20

# IWE OWE

**(B.C. 1000–1015)**

## ORI 1.

**Ète ọ̀rọ̀ Solomoni.**

OWE Solomoni, ọmọ Dafidi, ọba Israẹli. (1 A.Ọba 4:32; Onws 12: 9.)

2. Lati mọ ọ́gbọ́n ati ẹ̀kọ́; lati mọ ọ̀rọ̀ òye;

3. Lati gba ẹ̀kọ́ ọgbọ́n, ododo, ati idajọ, ati àìṣègbè; (Owe 19:20; 2:9.)

4. Lati fi òye fun alâìmọ̀kan, lati fun ọdọmọkunrin ni ìmọ̀ ati ìronú. (Owe 8:5,12; 2:10,11.)

5. Ọlọ́gbọ́n yoo gbọ́, yoo si máa pọ si i ni ẹ̀kọ́; ati ẹni òye yoo gba ìmọ̀ ọgbọ́n: (Owe 9:9; 14:6.)

6. Lati mọ òwe, ati ìtumọ̀; ọ̀rọ̀ ọgbọ́n, ati ọ̀rọ̀ ìkọ̀kọ̀ wọn. (Psm 78; 2.)

**Ìbẹ̀rù Oluwa – ipilẹṣẹ ìmọ̀.**

7. Ìbẹ̀rù Oluwa ni ipilẹṣẹ ìmọ̀; ṣugbọn awọn aṣiwere gan ọgbọ́n ati ẹ̀kọ́. (Job 28:28; Psm 111:10; Onws 12:13.)

**Ìkìlọ̀ lori ìwà-ipá.**

8. Ọmọ mi, gbọ́ ẹ̀kọ́ baba rẹ, ki iwọ ma si kọ ofin ìyá rẹ sílẹ̀: (Owe 4:1; 6:20.)

9. Nitori pe awọn ni yoo ṣe adé ẹwà fun ori rẹ, ati ọ̀ṣọ́ yi ọrùn rẹ ká. (Owe 4:9; Gen 41:42.)

10. Ọmọ mi, bi awọn ẹlẹ́ṣẹ̀ bá tàn ọ, ìwọ má ṣe gbà. (Deut 13:8; Ef 5:11.)

11. Bi wọn wi pe, "Wa pẹlu wa, jẹ ki a ba fun ẹ̀jẹ̀, jẹ ki a lugọ ni ìkọ̀kọ̀ de aláìṣẹ̀ lainidí. (Owe 12:6; ẹsẹ 18.)

12. Jẹ ki a gbe wọn mì láàyè bi isà-òkú; ati awọn ẹni-diduroṣinṣin bi awọn ti nlọ sinu ihò: (Psm 124:3; 28:1.)

13. Awa o ri oniruuru ọrọ̀ iyebiye, awa o fi ikogun kún ile wa:

14. Da ìpín rẹ pọ̀ mọ aarin wa; jẹ ki gbogbo wa jọ ni àpò kan:"

15. Ọmọ mi, máṣe rin ni ọ̀nà pẹlu wọn: fa ẹsẹ̀ rẹ sẹ́hìn kuro ni ipa-ọ̀nà wọn: (Psm 1:1; 119:101.)

16. Nitori ti ẹsẹ̀ wọn sure si ibi, wọn si yara lati ta ẹ̀jẹ̀ sílẹ̀. (Isa 59:7.)

17. Nitootọ, lásán ni a na àwọ̀n sílẹ̀ ni oju ẹyẹkẹ́yẹ.

18. Awọn wọnyìí si ba fun ẹ̀jẹ̀ ara wọn; wọn lùmọ̀ nikọ̀kọ̀ fun ẹ̀mí ara wọn.

19. Bẹẹ ni ọ̀nà gbogbo awọn ti nwá èrè pẹlu ipá; oun si ngba ẹ̀mí awọn ẹni ti o gba ohun o lohun (Owe 15:27; 5:22.)

**Ó léwu lati gan ọgbọ́n.**

20. Ọgbọ́n nkigbe lode; o nfọhùn rẹ ni igboro: (Owe 8:1.)

21. O nke ni ibi pataki apejọ, ni gbangba ẹnubodè ìlú, o sọ ọ̀rọ̀ rẹ wi pe,

22. "Yoo ti pẹ tó, ẹ̀yin alaimọkan ti ẹ̀yin o fi maa fẹ aimọkan? Ati ti awọn ẹlẹ́gàn yoo fi maa ṣe inudidun ninu ẹ̀gàn wọn, ati ti awọn aṣiwere (òmùgọ̀) yoo fi maa korira ìmọ̀? (ẹsẹ 4,32; Psm 1:1; ẹsẹ 29.)

23. Ẹ yipada ni ibawi mi; kiyesi i, emi o da ẹmi mi sinu yin, emi o fi ọ̀rọ̀ mi hàn fun yin. (Joel 2:28.)

24. Nitori ti emi pè, ti ẹ̀yin si kọ̀; ti emi na ọwọ mi, ti ẹnikan kò si ka a si: (Isa 65:12; Sek 7:11; Rom 10:21.)

25. Ṣugbọn ẹ̀yin ti ṣá gbogbo amọran mi tì, ẹ̀yin kò si fẹ́ ìbáwí mi: (Psm 107:11; Luk 7:30; Owe 15:10.)

26. Emi pẹlu o rẹrin idaamu yin; emi o ṣe ẹ̀fẹ̀ nigba ti ibẹru yin ba dé; (Psm 2:4; Owe 6:15; 10:24.)

27. Nigba ti ibẹru yin ba de bi ìjì, ati idaamu yin bi àfẹ́yíká-ìjì; nigba ti wahala ati ipọnju ba dé si yin.

28. Nigba naa ni ẹ̀yin o ke pè mi, ṣugbọn emi ki yoo dáhùn; wọn o ṣafẹri

mi ni kutukutu, ṣugbọn wọn ki yoo ri mi: (Isa 1:15; Esk 8:18; Sek 7:13.)

29. Nitori ti wọn korira ìmọ̀, wọn kò si yan ìbẹ̀rù Oluwa.

30. Wọn kò fẹ ìmọ̀ràn mi: wọn gan gbogbo ìbáwí mi. (Psm 81:11.)

31. Nitori naa ni wọn o ṣe maa jẹ ninu èrè iwa ara wọn, wọn o si kun fun ìmọ̀kímọ̀ wọn. (Job 4:8; Owe 14:14; Isa 3:11; Jer 6:19.)

32. Nitori pé irora awọn alaímọ̀kan ni yoo pa wọn, ati alaafia awọn aṣiwere ni yoo pa wọn run. (Jer 2:19.)

33. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba feti si mi yoo maa gbe lailewu, yoo si farabalẹ kuro ninu ìbẹ̀rù ibi." (Psm 25:12.)

## ORI 2.

**Èrè wíwá ọgbọ́n.**

OMỌ mi, bi iwọ yoo ba gba ọ̀rọ̀ mi, ki iwọ si pa ofin mi mọ́ pẹlu rẹ, (Owe 4:10.)

2. Ti iwọ sì dẹ eti rẹ silẹ̀ si ọgbọ́n, ti iwọ si fi ọkàn si òye; (Owe 3:1.)

3. Ani bi iwọ ba nke tọ ìmọ̀ lẹhin, ti iwọ si gbé ohùn rẹ sókè fun òye;

4. Bi iwọ ba ṣafẹri rẹ̀ bi fadaka, ti iwọ si nwa a kiri bi iṣura ti a pamọ; (Owe 3:14; Matt 13:44.)

5. Nigba naa ni iwọ o mọ ibẹru Oluwa, iwọ o si ri ìmọ̀ Ọlọrun. (Owe 1:7.)

6. Nitori Oluwa ni nfi ọgbọ́n funni: lati ẹnu rẹ̀ jade ni ìmọ̀ ati òye ti nwá. (1 A.Ọba 3:9,12; Jak 1:5.)

7. Ó to igbala jọ fun awọn olododo: oun ni asà fun awọn ti nrin deede. (Psm 84:11.)

8. O pa ipa-ọ̀nà idajọ mọ́, ọ si pa ọ̀nà awọn ayanfẹ rẹ̀ mọ. (1 Sam 2:9; O.D. 66:9.)

9. Nigba naa ni iwọ o mọ ododo, ati idajọ, ati aiṣègbè; ání, gbogbo ipa-ọ̀nà rere. (Owe 8:20; 4:18.)

10. Nigba ti ọgbọ́n ba wọ inu rẹ lọ, ti ìmọ̀ si dun mọ ọkàn rẹ̀: (Owe 14:33; 22:18.)

11. Imòye yoo pa ọ mọ, òye yoo si maa ṣọ́ ọ: (Owe 6:22.)

12. Lati gbà ọ ni ọwọ ẹni-ibi, ni ọwọ́ ọkunrin ti nsọrọ àyídáyidà;

13. Ẹni ti o fi ipa-ọ̀nà iduroṣinṣin silẹ̀, lati rin ni ọ̀nà òkùnkùn: (Jhn 3:19.)

14. Ẹni ti ó yọ̀ ninu ṣíṣe buburu, ti o ṣe inú-dídùn si àyídáyidà awọn eniyan buburu; (Owe 10:23; Jer 11:15.)

15. Ọ̀nà ẹni ti o wọ́, wọn si ṣe àrékérekè ni ipa-ọ̀nà wọn:

16. Lati gbà ọ ni ọwọ́ àjèjì obinrin, ani ni ọwọ́ àjèjì obinrin ti nfi ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ pọ́nni; (Owe 6:24; 23:27.)

17. Ẹni ti o kọ̀ olubákẹ́gbẹ́ ìgbà-ewe rẹ̀ silẹ̀, ti o si gbagbe majẹmu Ọlọrun rẹ̀. (Mal 2:14,15.)

18. Nitori pe ilé rẹ̀ tẹ̀ sínú ikú, ati ipa-ọ̀nà rẹ̀ sọdọ awọn òkú. (Owe 7:27.)

19. Kò si ẹni ti o tọ ọ lọ ti o si tun pada sẹhin, bẹẹ ni wọn ki i de ipa-ọ̀nà ìyè.

**Rínrìn lọ́nà ọgbọ́n.**

20. Ki iwọ le maa rin ni ọ̀nà eniyan rere, ki iwọ si pa ọ̀nà awọn olododo mọ́.

21. Nitori pé ẹni-iduroṣinṣin ni yoo jokòó ni ilẹ̀ naa, awọn ti o pé yoo si maa wà ninu rẹ̀. (Psm 37:29; 28:10.)

22. Ṣugbọn awọn eniyan buburu ni a o gé kúrò ni ilẹ̀ ayé, ati awọn olurekọja ni a o si fa tu kuro ninu rẹ̀. (Psm 37:38; Deut 28:63.)

## ORI 3.

**Ibukun ọgbọ́n.**

OMỌ mi, máṣe gbagbe ofin mi; si jẹ ki aya rẹ o pa ofin mi mọ́. (Owe 4:5; Eks 20:6; Deut 30:16.)

2. Nitori ọjọ gígùn, ati ẹ̀mí gígùn, ati alaafia ni wọn o fi kun un fun ọ. (Owe 4:10; Psm 119:165.)

3. Má ṣe jẹ ki aanu ati otitọ fi ọ silẹ: so wọn mọ́ ọrùn rẹ; kọ wọ́n si wàláà àyà rẹ: (2 Sam 15:20; Owe 1:9; 7:3.)

4. Bẹẹ ni iwọ o ri ojurere, ati ọna

nere loju Ọlọrun ati eniyan. (Owe 8:5; Psm 111:10.)

5. Fi gbogbo àyà rẹ gbẹkẹle Oluwa; má si ṣe tẹ̀ si ìmọ̀ ara rẹ. (Psm 37:3,5; Jer 9:23.)

6. Mọ ọn ni gbogbo ọ̀nà rẹ: oun o si maa tọ ipa-ọ̀nà rẹ. (1 Kro 28:9; Isa 45:13.)

7. Máṣe jẹ ọlọgbọ́n lójú ara rẹ; bẹ̀rù Oluwa, ki o si kuro ninu ibi. (Rom 12:16; Owe 16:6.)

8. Oun o ṣe ilera si ẹran-ara rẹ, ati itura si egungun rẹ: (Job 21:24.)

9. Fi ohun-ini rẹ bọ̀wọ̀ fun Oluwa, ati lati inu gbogbo akọbi ibisi-oko rẹ. (Isa 43:23; Eks 23:29.)

10. Bẹẹ ni àká rẹ yoo kun fun ọpọlọpọ, ati àgbá rẹ yoo si kun fun ọti-waini titun. (Deut 28:8.)

11. Ọmọ mi, máṣe kọ ibawi Oluwa; bẹẹ ni ki agara itọni rẹ̀ máṣe dá ọ: (Heb 12:5,6.)

12. Nitori pe ẹni ti Oluwa fẹ oun ni o ntọ́, gẹgẹ bi baba ti ntọ ọmọ ti inu rẹ dùn si. (Deut 8:5.)

**Ọgbọn níye lórí ju ọrọ̀ lọ.**

13. Ibukun ni fun ọkunrin naa ti o wa ọgbọ́n ri, ati ọkunrin naa ti o gba òye. (Owe 8:32,34.)

14. Nitori ti owó rẹ̀ ju owó fadaka lọ, èrè rẹ̀ si ju ti wúrà daradara lọ. (Job 28:13; Owe 8:10,19.)

15. O ṣe iyebiye ju iyùn lọ: ati ohun gbogbo ti iwọ le fẹ́, ko si eyi ti a le fi we e. (Job 28:18; Owe 8:11.)

16. Ọjọ gígùn nbẹ ni ọwọ́ ọ̀tún rẹ̀; ati ni ọwọ́ òsì rẹ̀, ọrọ̀ ati ọlá, (Owe 8:18.)

17. Ọ̀nà rẹ̀, ọ̀nà dídùn ni, ati gbogbo ipa-ọ̀nà rẹ̀, alaafia. (Owe 16:7.)

18. Igi ìyè ni i ṣe fun gbogbo àwọn ti o di i mu: ibukun si ni fun ẹni ti o di i mu ṣinṣin. (Owe 11:30; Gen 2:9.)

19. Ọgbọ́n ni Oluwa fi fi ìdí ayé sọlẹ, oye ni o si fi pèsè awọn ọrun. (Psm 104:24.)

20. Nipa ìmọ̀ rẹ ni ibú ya sókè, ti ikuukuu àwọsánmà si nsẹ ìrì rẹ̀ silẹ. (Gen 7:11; Job 36:28.)

**Ọlọgbọn jogun iyì.**

21. Ọmọ mi, máṣe jẹ ki wọn o lọ kuro ni ojú rẹ: pa ọgbọ́n ti o yè, ati ìmoye mọ́:

22. Bẹẹ ni wọn o maa jẹ ìyè si ọkàn rẹ, ati oore-ọfẹ si ọrùn rẹ. (Owe 4:22; 1:9.)

23. Nigba naa ni iwọ o maa rin ọ̀nà rẹ lailewu, ẹsẹ̀ rẹ ki yoo si kọ. (Owe 7:2.)

24. Nigba ti iwọ dubulẹ, iwọ ki yoo bẹ̀rù: nitootọ, iwọ o dubulẹ, oorun rẹ yoo si dùn. (Psm 3:5.)

25. Máṣe fòyà ẹ̀rù òjiji, tabi iparun awọn eniyan buburu, nigba ti o ba dé. (Psm 91:5; Job 5:21.)

26. Nitori Oluwa ni yoo ṣe ìgbẹkẹle rẹ, yoo si pa ẹsẹ̀ rẹ mọ́ kuro ninu gbígbámú.

27. Máṣe fawọ́ ire sẹhin kuro lọdọ ẹni ti nṣe tirẹ̀, bi o ba wa ni agbara ọwọ́ rẹ lati ṣe e. (Rom 13:7; Gal 6:10.)

28. Máṣe wi fun ẹnikeji rẹ pé, "Lọ, ki o si padà wa, bi o ba si di ọla, emi o fi fun ọ;" nigba ti iwọ ni i lọwọ rẹ. (Lef 19:13.)

29. Máṣe gbìrò buburu si ọmọnikeji rẹ, bi oun ti jokòó laibẹru lẹba ọ̀dọ̀ rẹ. (Owe 14:22.)

30. Máṣe ba eniyan jà lainidi, bi oun ko ba ṣe ọ ni ibi. (Rom 12:18.)

31. Máṣe ṣe ìlara oniwa-ipa, ma si ṣe yan ọkan ninu gbogbo ọ̀nà rẹ̀. (Psm 37:1; Owe 24:1.)

32. Nitori pe irira ni alaigbọran loju Oluwa; ṣugbọn aṣiri rẹ̀ wa pẹlu awọn olododo. (Owe 11:20; Psm 25:14.)

33. Ègún Oluwa nbẹ ni ile awọn eniyan buburu: ṣugbọn o bukun ibugbe awọn olootọ. (Deut 11:28; Mal 2:2; Job 8:6.)

34. Nitootọ o kẹ́gàn awọn ẹlẹ́gàn: ṣugbọn o fi oore-ọfẹ fun awọn onírẹ̀lẹ̀. (Jak 4:6; 1 Pet 5:5.)

35. Awọn ọlọgbọ́n ni yoo jogún ogo: ṣugbọn awọn aṣiwere (òmùgọ̀) ni yoo ru ìtìjú wọn.

ORI 4.

**Àṣẹ fun ọmọ lati wa ọgbọ́n ri.**

EYIN ọmọ, ẹ gbọ́ ẹkọ́ baba, ki ẹ si fiyesi ati mọ òye. (Owe 1:8; 2:2.)
2. Nitori ti mo fun yin ni ẹ̀kọ́ rere, ẹ máṣe kọ ofin mi silẹ.
3. Nigba ti emi wa ni ọmọde pẹlu baba mi, ẹni-ìkẹ́ ati ọlufẹ ni oju ìyá mi. (1 Kor 22:5.)
4. Oun si kọ́ mi pẹlu, o si wi fun mi pe, "Jẹ ki àyà rẹ o gba ọ̀rọ̀ mi duro: pa ofin mi mọ ki ìwọ si yè. (1 Kro 28:9; Owe 7:2.)
5. Ni ọgbọ́n, ni òye: máṣe gbagbe; bẹẹ ni ki iwọ máṣe fa sẹhin kuro ni ọ̀rọ̀ ẹnu mi. (ẹsẹ 7; Owe 16:16.)
6. Máṣe kọ̀ ọ sílẹ̀, yoo si mu ọ tọ́: fẹ ẹ, yoo si pa ọ mọ́. (2 Tess 2:10.)
7. Ipilẹṣẹ ọgbọ́n ni lati ni ọgbọ́n: ati pẹlu iní rẹ gbogbo, ni oye. (Owe 23:23.)
8. Gbe e ga, oun o si maa gbe ọ lékè: oun o mu ọ wa si ọlá, nigba ti iwọ ba gbá a mọra. (1 Sam 2:30.)
9. Oun o fi ohun-ọ̀ṣọ́ daradara si ọ ni orí: oun o fi ọjá daradara fun ori rẹ." (Owe 1:9.)

**Ìyàtọ̀ laarin ọgbọ́n ati ibi.**

10. Gbọ, iwọ ọmọ mi, ki o si gbà ọ̀rọ̀ mi; ọdún ẹmi rẹ yoo si di pupọ. (Owe 2:1; 3:2.)
11. Emi ti kọ́ ọ ni ọ̀nà ọgbọ́n; emi ti mu ọ tọ ipa-ọ̀nà títọ́. (1 Sam 12:23.)
12. Nigba ti iwọ nrin, ọ̀nà rẹ ki yoo há fun àyè; nigba ti iwọ nsare, iwọ ki yoo fi ẹsẹ̀ kọ. (Psm 18:36; Owe 3:23.)
13. Di ẹ̀kọ́ mu ṣinṣin, máṣe jẹ ki o lọ; pa a mọ́, nitori oun ni ẹ̀mí rẹ.
14. Máṣe bọ si ipa-ọ̀nà eniyan buburu, ma si ṣe rin ni ọ̀nà awọn eniyan ibi. (Psm 1:1; Owe 1:15.)
15. Yẹ ẹ silẹ, máṣe kọja ninu rẹ̀, yẹ kuro nibẹ, si máa ba tirẹ lọ.
16. Nitori ti wọn ki i sùn bikoṣe pe wọn huwa buburu; oorun kò sí fún wọn, bikoṣe pe wọn ba mu eniyan ṣubú. (Psm 36:4; Mika 2:1.)
17. Nitori ti wọn njẹ ounjẹ ìwà-ìkà, wọn si nmu ọti-waini iwa-agbara.
18. Ṣugbọn ipa-ọ̀nà awọn olootọ dabi titan ìmọ́lẹ̀, ti o ntan siwaju ati siwaju titi di ọ̀sán-gangan. (Isa 26:7; 2 Sam 23:4; Dan 12:3.)
19. Ọ̀nà awọn eniyan buburu dabi okùnkùn: wọn ko mọ ohun ti wọn nkọlù. (Job 18:5; Isa 59:9,10; Jer 23:12; Jhn 12:35.)

**Àṣẹ ti o ṣe iyebiye fun ọmọ.**

20. Ọmọ mi, feti si ọ̀rọ̀ mi; dẹ etí rẹ silẹ si ọ̀rọ̀ mi.
21. Máṣe jẹ ki wọn o lọ kuro ni oju rẹ; pa wọn mọ ni aarin àyà rẹ. (Owe 3:21; 7:1,2.)
22. Nitori ìyè ni wọ́n nṣe fún awọn ti o wá wọn ri, ati ìmularada si gbogbo ẹran-ara wọn. (Owe 3:8; 12:18.)
23. Pa àyà rẹ mọ pẹlu ìṣọ́ra gbogbo; nitori pé lati inu rẹ̀ wa ni orísun ìyè. (Matt 12:34; Mk 7:21; Luk 6:45.)
24. Mu arekereke kuro lọ́dọ̀ rẹ, ati ètè ẹ̀tàn jinna réré kuro lọdọ rẹ. (Owe 6:12; 19:1.)
25. Jẹ ki oju rẹ maa wò ọ̀kánkán gan, ki o si jẹ ki itẹjumọ-oju rẹ wa ni iwaju rẹ.
26. Ronu ipa-ọ̀nà rẹ, gbogbo ọ̀nà rẹ ni yoo si fi idi mulẹ. (Heb 12:13; Psm 119:5.)
27. Máṣe yà si apa ọ̀tún tabi si apá òsì, si ẹsẹ̀ rẹ kuro ninu ibi. (Deut 5:32; 28:14; Owe 1:15.)

ORI 5.

**Ìkilọ̀ lórí ìwà kiko ìbáwí.**

OMỌ mi, fiyesi ọgbọ́n mi, ki o si dẹ etí rẹ si òye mi. (Owe 4:20; 22:17.)
2. Lati maa pa ironu mọ, ati ki ètè rẹ le maa pa ìmọ̀ mọ́. (Mal 2:7.)
3. Nitori ti ètè àwọn ajeji obinrin a maa kán bi oyin, ẹnu rẹ̀ si kunna ju ororo lọ: (Owe 2:16; Psm 55:21.)
4. Ṣugbọn igbẹhin rẹ̀ koro bi iwọ, o si mú bi idà olojumeji. (Owe 7:26; Psm 57:4.)

5. Ẹsẹ rẹ nsọkalẹ lọ sinu ikú, ìrìn-ẹsẹ rẹ ntẹlẹ ọ̀nà ipò-okú. (Owe 7:27.)
6. Oun kò kíyèsi ipa-ọ̀nà ìyè, ipa-ọ̀nà rẹ a mà yi sihin yi sọhun, oun ko si mọ̀.
7. Njẹ gbọ temi nisisiyi, ẹyin ọmọ, ki ẹyin máṣe ya kuro ni ọrọ ẹnu mi. (Owe 7:24; Psm 119:102.)
8. Takete kuro lọdọ rẹ, ma si ṣe súnmọ́ eti ilẹ̀kùn ile rẹ̀: (Owe 7:25; 9:14.)
9. Ki iwọ ma baa fi ọlá rẹ fun ẹlomiran, ati ọdún rẹ fun alailaanu;
10. Ki a má ba fi ọrọ̀ rẹ kun àjèji ènìyan; ki èrè-iṣẹ́ ọwọ́ rẹ má baa wà ni ile àlejò.
11. Iwọ a si maa kaanu ni ikẹhin ayé rẹ, nigba ti ẹran-ara ati ara rẹ bá parun.
12. Iwọ a si wi pe, "Emi ti korira ẹ̀kọ́ tó; ti àyà mi si gan ìbáwí!" (Owe 1:29; 12:1.)
13. Ti emi ko gba ohun àwọn olukọ mi gbọ, tabi ki emi dẹ eti mi silẹ si awọn ti nkọ mi.
14. Emi si ti wa lẹnu ọ̀nà ibi patapata lãrin awujọ, ati ni ìjọ.

**Ayọ̀ igbeyawo ati ojuṣe.**

15. Mu omi lati inu àmù rẹ, ati omi ti nṣan lati inu kọ̀nga rẹ.
16. Ṣe o tọ́ ki ìsun rẹ̀ o ṣàn kakiri, ati àwọn odò omi rẹ ni ìta? (Owe 9:17.)
17. Jẹ ki wọn jẹ kìkì tirẹ, ki o má ṣe jẹ́ ti awọn ajeji ti o wà pẹlu rẹ.
18. Jẹ ki orisun rẹ o ni ibukun: ki iwọ si maa yọ iwọ ati aya igba-èwe rẹ. (Onws 9:9; Mal 2:14.)
19. Jẹ ki ọmú rẹ̀ maa fi ayọ̀ kún ọ nigbagbogbo; bi abo agbọnrin daradara ani abo agbọnrin ti o kun fun oore-ọ̀fẹ́, ki o si maa yọ̀ gidigidi ninu ifẹ rẹ̀ nigbakugba. (O.Sol. 2:9; 4:5; 7:3.)
20. Ọmọ mi, eeṣe ti iwọ o fi maa yọ̀ ninu ìfẹ́ àjèji obinrin, ti iwọ o fi gbá aya ajeji obinrin mọra? (Owe 2:16; 7:5.)
21. Nitori pe ọ̀nà eniyan nbẹ niwaju Oluwa, o si nsọ ọ̀nà wọn gbogbo. (Job 31:4; 34:21; Owe 15:3; Jer 16:17; 32:19; Hos 7:2; Heb 4:13.)
22. Ẹ̀ṣẹ̀ ẹni-buburu ni yoo mu ountikararẹ̀, okùn ẹ̀ṣẹ ara rẹ̀ yoo si di i mu. (Psm 9:15.)
23. Yoo kú ni aigba ẹ̀kọ́, ati ninu ọpọlọpọ were (òmùgọ̀) rẹ̀ yoo si maa ṣina kiri. (Job 4:21; 36:12.)

## ORI 6

**Ìkìlọ̀ nipa jíjẹ́ oluṣe ọ̀rọ̀ náà.**

OMỌ mi, bi iwọ ba ṣe onigbọ̀wọ́ fun ọ̀rẹ́ rẹ, ti o si mu ògò rẹ fun àjèji eniyan. (Owe 11:15; 17:18; 20:16; 22:26; 27:13.)
2. Bi a ba fi ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ dẹkùn fun ọ, ti a si fi ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ mu ọ;
3. Njẹ, saa ṣe èyí, ọmọ mi, ki o si gba ara rẹ silẹ, nitori ti iwọ ti bọ si ọwọ́ aladugbo rẹ; lọ, rẹ ara rẹ silẹ, ki iwọ si tu aladugbo rẹ loju.
4. Máṣe fi oorun fun oju rẹ, tabi òògbé fun ipenpeju rẹ (Psm 132:4.)
5. Gba ara rẹ bi abo agbọnrin ni ọwọ́ ọdẹ, ati bi ẹyẹ ni ọwọ́ apẹyẹ. (Psm 91:3.)

**Ọlẹ kò dára.**

6. Tọ èèrùn lọ, iwọ ọlẹ: kiyesi iṣẹ́ rẹ̀ ki o si gbọ́n: (Owe 30:24,25.)
7. Ti ko ni onidajọ, alabojuto, tabi alakoso.
8. Ti npese ounjẹ rẹ ni igba-ẹ̀ẹ̀rùn, ti o si nkó ounjẹ rẹ jọ ni igba ìkórè. (Owe 10:5.)
9. Ọlẹ, ìwọ o ti sun pẹ́ to? Nigbawo ni iwọ o dide kuro ninu orun rẹ? (Owe 24:33.)
10. Orun diẹ si i, òògbé diẹ si i, ikawọkòpọ lati sun diẹ:
11. Bẹẹ ni òṣì rẹ yoo de bi alarinkiri, ati aini rẹ bi ọkunrin ti o hamọran ogun. (Owe 10:4; 13:4; 20:4.)

**Ìkìlọ̀ lori gbingbin èso ìkà.**

12. Eniyan-keniyan, ọkunrin buburu, ti o nrin ti oun ti ẹnu àrékérekè. (Owe 16:27; 10:32.)
13. O nṣeju rẹ̀, o nfi ẹsẹ̀ rẹ̀ sọrọ, o

nfi ìka rẹ̀ ṣe ajúwe. (Psm 35:19; Owe 10:10.)

14. Àrékérekè nbẹ ni àyà rẹ̀, o gbimọ iwa-ìkà nigbagbogbo; o nda ija silẹ. (Mika 2:1; ẹsẹ 19.)

15. Nitori naa ni ipọnju rẹ̀ yoo de si i lojiji; ojiji ni yoo dá gbáú laini àtúnṣe: (Owe 24:22; Jer 19:11; 2 Kro 36:16.)

**Ohun meje ti Ọlọrun korira.**

16. Ohun mẹfa ni Oluwa korira: nitootọ, meje ni o ṣe ìrira fun ọkàn rẹ̀;

17. Ojú ìgbéraga, ètè èké, ati ọwọ ti nta ẹ̀jẹ̀ alâìṣẹ̀ sílẹ̀. (Psm 18:27; 120:2; Isa 1:15.)

18. Àyà ti ngbimọ buburu, ẹsẹ̀ ti o yara ni iré sísá sí ìwà-ìkà. (Gen 6:5; Owe 1:16.)

19. Ẹlẹri èké ti nsọ èké jade, ati ẹni ti nda ìjà silẹ laarin awọn arakunrin. (Psm 27:12; ẹsẹ 4.)

**Ìkìlọ̀ lórí panṣaga.**

20. Ọmọ mi, pa àṣẹ baba rẹ mọ́, ki iwọ o ma si ṣe kọ òfin ìyá rẹ silẹ: (Owe 7:1; 1:8.)

21. Dì wọn mọ àyà rẹ nigbagbogbo, ki o si só o mọ́ ọrùn rẹ. (Owe 3:3.)

22. Nígba ti iwọ ba nrin, yoo maa ṣe amọ̀nà rẹ; nigba ti iwọ ba sùn, yoo maa ṣọ ọ; nigba ti iwọ ba sì ji, yoo si maa ba ọ sọ̀rọ̀. (Owe 3:23,24.)

23. Nitori pe ofin ni fitila; kíkọ́ni si ni ìmọ́lẹ̀; ati awọn ibawí ti ntọ́nisọ́nà, ní ọ̀nà ìyè: (Psm 19:7–14.)

24. Lati pa ọ mọ kuro lọwọ obinrin buburu, lọwọ ahọ́n ipọnni àjèjì obinrin. (Owe 2:16; 5:3.)

25. Máṣe ṣe ifẹkúfẹ ẹwà rẹ ni aya rẹ; bẹẹ ni ki o ma si ṣe jẹ ki oun o fi ipenpeju rẹ mu ọ. (Matt 5:28.)

26. Nitori pe nipasẹ agbere-obinrin ni eniyan fi ndi onisu-akara kan: bẹẹ ni panṣaga-obinrin a maa lépa ayé eniyan lati parun. (Owe 29:3; 7:23; Esk 13:18.)

27. Ọkunrin ha lè gbé iná si àyà rẹ ki aṣọ rẹ o má jona bi?

28. Ẹnikan ha le gun ori ẹyin-iná gbigbona, ki ẹsẹ̀ rẹ̀ o má jona bi?

29. Bẹẹ ni ẹni ti o wọle tọ obinrin ẹni-keji rẹ̀ lọ; ẹnikẹni ti o fi ọwọ́ bà á, ki yoo lọ ni àìjìyà. (Esk 18:6; 33:26.)

30. Njẹ awọn eniyan ki i gan olè, bi o ba ṣe pe, o jalè lati tẹ́ ọkàn rẹ̀ lọ́rùn, nigba ti ebi npa a?

31. Ṣugbọn bi a ba mu un, yoo san an pada niwọn meje; gbogbo ini ilé rẹ̀ ni yoo fi san ẹ̀san. (Eks 22:1–4.)

32. Ṣugbọn ẹni ti o ba bá obinrin ṣe panṣaga, ko ni òye: ẹni ti o ba ṣe e yoo pa ẹ̀mí ara rẹ run. (Owe 7:7.)

33. Ọgbẹ́ ati àbùkù ni yoo ni; ẹ̀gàn rẹ̀ ki yoo si kúrò.

34. Nitori owú ni ibinu ọkunrin: nitori naa ki yoo dási lọjọ ẹ̀san. (Owe 27:4; 11:4.)

35. Oun ki yoo nani owó idande, bẹẹ ni inú rẹ̀ ki yoo dun, bi iwọ tilẹ̀ sọ ẹ̀bùn rẹ̀ di pupọ.

## ORI 7.

**Yẹra fún ẹ̀tàn panṣaga-Obinrin.**

ỌMỌ mi, pa ọ̀rọ̀ mi mọ́, ki o si to ofin mi bi iṣura pẹlu rẹ. (Owe 2:1.)

2. Pa ofin mi mọ, ki o si yè; ati àṣẹ mi bi ọmọloju rẹ. (Owe 4:4; Deut 32:10.)

3. Dì wọn mọ́ ìka rẹ, kọ wọn si wàláà àyà rẹ. (Deut 6:8; Owe 3:3.)

4. Wi fún ọgbọ́n pé, "Iwọ ni arabinrin mi; "ki o si pe òye ni ibatan rẹ obinrin:

5. Ki wọn le pa ọ mọ́ kuro lọwọ obinrin ẹlomiran, lọwọ àjèjì ti nfi ọ̀rọ̀ rẹ̀ ṣe ipọnni. (Owe 2:16; 5:3; 6:24.)

6. Ni ojú fèrèsé ile mi ni emi saa bojúwò laarin fèrèsé mi.

7. Mo si ri ninu awọn òpè, mo kiyesi ninu awọn ọmọkunrin, ọmọkunrin kan ti ko ni òye. (Owe 1:22; 6:32.)

8. O nkọja lọ ni igboro ni etí igun ile rẹ̀; o si lọ si ọ̀nà ile rẹ̀ (ẹsẹ 12,27.)

9. Ni wiriwiri imọlẹ, ni àṣálẹ́, ni òru dúdú ati òkùnkùn: (Job 24:15.)

10. Ṣi kiyesi i, obinrin kan pade rẹ̀, o wọ aṣọ bi panṣaga-obinrin; alárekérekè àyà.

11. O jẹ aláriwo ati agídí; ẹsẹ̀ rẹ̀ ki i duro ni ilé rẹ̀. (Owe 9:13; 1 Tim 5:13.)

12. Nisinsinyìí o jade, nisinsinyìí o wà ni igboro, o si nba ni ibi igun ile gbogbo. (Owe 23:28.)

13. O di i mu, o si fẹnu ko o lẹnu, o si fi ọ̀dájú wi fun un pé,

14. "Ọrẹ́, alaafia nbẹ lọwọ mi, loni ni mo ti san ẹ̀jẹ́ mi." (Owe 7:11,16.)

15. Nitori naa ni mo ṣe jade wá pade rẹ, lati ṣe afẹri oju rẹ, emi si ri ọ.

16. Emi ti fi aṣọ títẹ́ ọlọnà tẹ àketè mi, ọlọnà finfin ati aṣọ ọ̀gbọ̀ daradara ti Egipti. (Owe 31:22; Isa 19:9.)

17. Emi ti fi turari oloorun dídùn ti mirra, aloe, ati kinnamoni si àketè mi.

18. Wá, jẹ ki a gbà ẹ̀kún ìfẹ́ wa titi yoo fi di owurọ, jẹ ki a fi ìfẹ́ tu ara wa lara.

19. Nitori pe baale mi ko si ni ile, o re àjò ọ̀nà jínjìn.

20. "O mu apo owó kan lọwọ rẹ̀, yoo si de ni oṣupa àrànmọ́jú."

21. Ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn daradara ni o fi yí i lọ́kàn pada, ìpọ́nni ètè rẹ̀ ni o fi mu un ni ipá. (Owe 5:3.)

22. Oun si tọ̀ ọ́ lọ lẹsẹkannaa bi malu ti nlọ si ibùpa, tabi bi aṣiwere (òmùgọ̀) ti nlọ si ibi amukọ́gbọ́n.

23. Titi ọfà fi gún un ni ẹ̀dọ̀; bi ẹyẹ ti nyara bọ sinu okùn, ti kò si mọ̀ pe fun ẹmi oun ni. (Onws 9:12.)

24. Njẹ nisinsinyìí, ẹ̀yin ọmọ, ẹ feti si temi, ki ẹ si fiye si ọ̀rọ̀ ẹnu mi. (Owe 5:7.)

25. Máṣe jẹ ki àyà rẹ o tẹ̀ si ọ̀nà rẹ, máṣe ṣina lọ si ipa-ọ̀nà rẹ. (Owe 5:8.)

26. Nitori ọ̀pọ̀lọpọ̀ eniyan ni o ti já balẹ̀; nitootọ ọpọlọpọ alagbara ni a ti ọwọ́ rẹ̀ pa. (Owe 9:18.)

27. Ilé rẹ̀ ni ọ̀nà isà-òkú, ti nsọkalẹ lọ si iyẹwu ikú. (Owe 2:18; 5:5; 9:18.)

## ORI 8.

**Ìpè ọgbọ́n.**

OGBỌ́N kò ha nkigbe bí? Òye ko ha gbe ohùn rẹ̀ soke bi? (Owe 1:20; 9:3.)

2. O duro lori awọn ibi-giga, lẹba ọ̀nà, ni ìpa-ọ̀nà ni o gẹ̀gùn si;

3. Ni ẹnu-ọ̀nà, ibode ìlú, ni àtiwọ ojú ilẹkun o nkigbe soke. (Job 29:7.)

4. "Ẹ̀yin eniyan ni emi npe; ohun mi si nkọ si awọn ọmọ eniyan."

5. Ẹyin òpè, ẹ mọ ọgbọ́n: ati ẹ̀yin aṣiwere (òmùgọ̀) ki ẹ ṣe aláyà òye. (Owe 1:4,22,32.)

6. Ẹ gbọ́, nitori ti emi o sọ̀rọ̀ ohun ti o dara, ati lati ètè mi ni ọ̀rọ̀ ohun títọ́ yoo ti wá. (Owe 32:20; 23:16.)

7. Nitori ti ẹnu mi yoo sọ̀rọ̀ otitọ; ìwà-buburu si ni ìríra fun ètè mi. (Psm 37:30.)

8. Ninu ododo ni gbogbo ọ̀rọ̀ ẹnu mi; ko si ẹ̀tàn kan tabi àrekérekè ninu wọn.

9. Gbangba ni gbogbo wọn jasi fun ẹni ti ó yè, o si tọ́ fun awọn ti o nwa ìmọ̀ ri. (Owe 14:6; 3:13.)

10. Gbà ẹ̀kọ́ mi, dípò fadaka; si gba ìmọ̀ ju wura àṣayan lọ. (Owe 3:14,15.)

11. Nitori ti ìmọ̀ jù iyùn lọ; ohun gbogbo ti a le fẹ, ko si eyi ti a le fi we e. (Job 28:18; Owe 3:15.)

12. Emi, ọgbọ́n, ni o nba ìmòye gbé, emi si ri ìmọ̀ ati ìmòye. (ẹsẹ 5; Owe 1:4.)

13. Ibẹ̀ru Oluwa ni ikorira ibi: irera, ati igberaga, ati ọ̀nà ibi, ati ẹnu àrekérekẹ̀, ni mo korira. (Owe 16:6; 16:18; 15:9; 6:12.)

14. Temi ni ìmọ̀ ati ọgbọ́n ti o yè: temi ni òye, temi ni agbára. (Owe 1:25; 2:7; Onws 7:19.)

15. Nipasẹ mi ni ọba nṣe akoso, ti awọn olori si nlana otitọ. (Dan 2:21; Rom 13:1.)

16. Nipasẹ mi ni awọn ijoye nṣolori, ati awọn olootọ́, ani gbogbo awọn onidajọ ayé.

17. Mo fẹ awọn ti o fẹ mi; awọn ti o si wá mi ni kutukutu (ayé wọn) yoo ri

mi. (1 Sam 2:30; Psm 91:14; Jhn 14:21; Jak 1:5.)

18. Ọrọ̀ ati ọlá nbẹ lọwọ mi, ani ọrọ̀ ati aásìkí ti nduro pẹ. (Owe 3:16; Matt 6:33.)

19. Èrè mi ta wura yọ, nitootọ, jù wura daradara lọ: ati ọrọ̀ mi ju fadaka àṣayan lọ. (Owe 3:14; 10:20.)

20. Emi nrin ni ọ̀nà ododo, laarin ipa-ọ̀nà idajọ:

21. Ki emi le mu awọn ti o fẹ mi jogun ohun-ini, emi o si fi kún iṣura wọn. (Owe 24:4.)

**Ohun ayeraye ni ọgbọ́n.**

22. Oluwa da mi ni ipilẹṣẹ iṣẹ́ rẹ̀, ṣaaju iṣẹ rẹ̀ atijọ. (Owe 3:19.)

23. A ti yàn mi lati ayérayé, lati ipilẹṣẹ, tabi ki ayé to wa. (Jhn 17:5.)

24. Nigba ti ọ̀gbun kò si, a ti bi mi; nigba ti ko si orisun ti o kún fun omi pupọ.

25. Ki a to fi idi awọn oke-nla sọlẹ̀, ṣaaju awọn okẹ ni a ti bi mi: (Psm 90:2.)

26. Nigba ti ko ti i da ayé, tabi pẹ̀tẹ́lẹ̀, tabi ori erupẹ ayé.

27. Nigba ti o nṣe ìpìlẹ̀ awọn ọ̀run, emi wà nibẹ: nigba ti o fi òṣùwọ̀n ayika le oju ọ̀gbun. (Owe 3:19; Job 26:10.)

28. Nigba ti o sọ awọsanma lọjọ̀ soke: nigba ti o fi agbara fun orisun ibú:

29. Nigba ti o fi àṣẹ rẹ̀ fun òkun, ki omi rẹ̀ má ṣe kọjá ẹnu rẹ̀: ati ofin rẹ fun ìpìlẹ̀ ayé. (Job 38:10; Psm 104:9; Job 38:6.)

30. Nigba naa, emi wa lọdọ rẹ̀, bi oníṣẹ́: emi si jẹ dídùn-inu rẹ̀ lojojumọ, emi nyọ nigbagbogbo niwaju rẹ̀; (Jhn 1:1–3.)

31. Emi nyọ ni ibi-itẹdo ayé rẹ̀; dídùn-inú mi si wà sipa awọn ọmọ eniyan. (Psm 16:3.)

**Gbọ́, ki o si gba ọgbọ́n.**

32. Njẹ nisinsinyìí, ẹ feti si temi, ẹ̀yin ọmọ: nitori pe ibukun ni fun awọn ti o tẹle ọ̀nà mi: (Owe 5:7; Psm 119:1,2; Luk 11:28.)

33. Gbọ́ ẹ̀kọ́, ki ẹ̀yin si gbọ́n, má si ṣe jẹ ki o lọ. (Owe 4:1.)

34. Ibukun ni fun ẹni ti o gbọ́ temi, ti o nṣọ́ ẹnu-ọ̀nà mi lojojumọ, ti o si nduro ti òpó ẹnu-ilẹkun mi. (Owe 3:13,18.)

35. Nitori pe ẹni ti o ri mi, o ri ìyè, yoo si ri ojurere Oluwa. (Owe 4:22; 12;2.)

36. Ṣugbọn ẹni ti o ṣẹ̀ mi, o ṣe ọkàn ara rẹ̀ níkà: gbogbo awọn ti o korira mi, wọn fẹ ikú." (Owe 20:2.)

## ORI 9.

**Ìpè ọgbọ́n.**

OGBỌN ti kọ́ ile rẹ, o si gbẹ́ ọ̀wọ̀n rẹ̀ meje: (Matt 16:18; Ef 2:20, 22; 1 Pet 2:5.)

2. O ti pa ẹran rẹ̀; o ti ṣe adalu ọti-waini rẹ̀; o si ti tẹ́ tabili rẹ̀. (Matt 22:4; Luk 14:16,17.)

3. O ti ran awọn ọmọbinrin rẹ̀ jade, o nke lori ibi giga ìlú, pé, (Psm 68:11; Matt 22:3; Owe 8:1,2.)

4. "Ẹnikẹni ti o se òpè ki o yà si ihin", fun ẹni ti òye kù fun, o wi pe, (Owe 8:5; 6:32.)

5. "Wa, jẹ ninu ounjẹ mi, ki o si mu ninu ọti-waini mi ti mo dàlù. (O.Sol. 5:1; Isa 55:1; Jhn 6:27.)

6. Kọ iwere silẹ ki o si yè; si maa rìn ni ọ̀nà òye." (Esk 11:20; 37:24.)

**Ìbẹ̀rù Ọlọrun ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n.**

7. Ẹni ti o ba ba ẹlẹ́gàn wi, yoo gba ìtìjú fun ara rẹ̀, ati ẹni ti o ba ba eniyan buburu wi yoo gba àbùkù rẹ̀. (Owe 23:9.)

8. Máṣe ba ẹlẹgan wi, ki o má baa korira rẹ, ba ọlọgbọn eniyan wi, yoo si maa fẹ ọ. (Matt 7:6; Psm 141:5.)

9. Fi ẹ̀kọ́ fun ọlọgbọ́n eniyan, yoo si maa gbọ́n siwaju, kọ́ eniyan olootọ: yoo si maa fẹ ọ. (Owe 1:5.)

10. Ibẹru Oluwa ni ipilẹṣẹ ọgbọ́n: ati ìmọ̀ Ẹni-Mimọ ni òye. (Job 28:28; Owe 1:7.)

11. Nitori nipasẹ mi ni ọjọ́ rẹ̀ yoo

maa lé si i, ati ọdún ìyè rẹ̀ yoo si maa lé si i. (Owe 3:16; 10:27.)

12. Bi iwọ ba gbọ́n, iwọ gbọ́n fun ara rẹ̀: ṣugbọn bi iwọ ba nṣe ẹlẹgan, ìwọ nikan ni yoo ru u. (Owe 19:29.)

**Ìpè òmùgọ̀ obinrin.**

13. Alaroye ni aṣiwere (òmùgọ̀) obinrin: òpè ni ko si mọ nkan. (Owe 7:11; 5:6.)

14. O saa jokòó ni ẹnu-ọ̀nà ilé rẹ̀, lori apoti, ni ibi giga ìlú. (ẹsẹ 3.)

15. Lati maa pe àwọn ti nkọja nibẹ, ti nrin ọ̀nà ganran wọn lọ: pé.

16. "Ẹnikẹni ti o ba ṣe òpè, ki o ya si ihin"; ẹni ti òye ku fun, o wi fun un pé, (ẹsẹ 4.)

17. "Omi olè dùn, ati ounjẹ ikọ̀kọ̀ si ṣe dídùn." (Owe 20:17.)

18. Ṣugbọn oun kò mọ̀ pe awọn okú wà nibẹ: ati pe awọn alapejẹ rẹ̀ wa ni isalẹ isà-òkú (Owe 7:27.)

## ORI 10.

**Ẹni ìdúróṣinṣin ati ẹni buburu.**

OWE Solomoni ni wọnyií. Ọlọgbọ́n ọmọ ṣe inu-didun baba rẹ̀, ṣugbọn aṣiwere (òmùgọ̀) ọmọ ni ibanujẹ ìyá rẹ̀. (Owe 1:1; 15:20; 29:3,15.)

2. Iṣura iwà-buburu kò ni èrè: ṣugbọn ododo ni ngbani kuro lọwọ ikú. (Psm 49:6; Owe 11:4; Luk 12: 19,20; Owe 11:4,60.)

3. Oluwa ki yoo jẹ ki ebi o pa ọkàn olododo; ṣugbọn o yi ìfẹ́ awọn eniyan buburu danu. (Psm 34:9,10; Matt 6:33; Psm 112:10.)

4. Ẹni ti o ba dẹ ọwọ́ a di talaka; ṣugbọn ọwọ́ awọn alaapọn ni nmu ọlà wá. (Psm 12:24; 13:4.)

5. Ẹni ti o ba kojọ ni igba-ẹ̀rùn ni ọlọgbọn ọmọ: ṣugbọn ẹni ti o ba nsùn ni igba ikore ni ọmọ ti ndoju ti ni. (Owe 6:8; 17:2.)

6. Ibukun wa lori olododo: ṣugbọn ẹnu eniyan buburu ni nbo iwà-ipá mọle. (Est 7:8.)

7. Ibukún ni iranti olootọ: ṣugbọn orukọ eniyan búburú yoo rà. (Psm 9:56; Onws 8:10.)

8. Ọlọ́gbọ́n inú ni yoo gba ofin: ṣugbọn ètè were (òmùgọ̀) ni a o parun. (Owe 13:3.)

9. Ẹni ti o nrin deede, o rin dajudaju: ṣugbọn ẹni ti o ba nṣe àyídà ọ̀nà rẹ̀, oun ni a o mọ̀. (Psm 23:4; Owe 28:18; Isa 33:15; Owe 26:26.)

10. Ẹni ti nṣe (idajọ) oju o mu ibanujẹ wá; *(ṣugbọn ẹni ti o fi igboya baniwi o nfẹ alaafia) ṣugbọn ete were (òmùgọ̀) ni a o parun. (Owe 16 :13.)

11. Kọ̀nga ìyè ni ẹnu olododo: ṣugbọn ẹnu eniyan buburu ni nbo iwà-ipá mọlẹ. (Psm 37:30.)

12. Ikorira ni nrú ìjà soke: ṣugbọn ìfẹ́ bo gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ mọlẹ. (1 Pet 4:8.)

13. Ni ètè ẹni ti o moye ni a ri ọgbọ́n: ṣugbọn kùmọ̀ ni fun ẹ̀hìn ẹni ti òye kù fun. (Owe 26:3.)

14. Awọn ọlọgbọ́n a maa to ìmọ̀ jọ: ṣugbọn ẹnu awọn aṣiwere (òmùgọ̀) sunmọ iparun. (Owe 9:9; 18:7.)

15. Ọrọ̀ ọlọ́lá ni ilu agbara rẹ̀: aini awọn talaka ni iparun wọn. (Job 31:24; Psm 52:7; Owe 18:11; 19:7.)

16. Iṣẹ́ olododo tẹ si ìyè; èrò awọn eniyan buburu si ẹ̀ṣẹ̀.

17. Ẹni ti o ba pa ẹ̀kọ́ mọ́, o wà ni ipa-ọ̀nà ìyè; ṣugbọn ẹni ti o ba kọ ibawi o ṣìnà. (Owe 6:23.)

18. Ẹni ti o ba pa ikorira mọ ni ètè èké, ati ẹni ti o ba nbanujẹ, aṣiwere (òmùgọ̀) ni. (Owe 26:24; Psm 15:3.)

19. Ninu ọ̀rọ̀ pupọ, a kò lè fẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ kù: ṣugbọn ẹni ti o pa ètè rẹ̀ mọ́ ni o gbọ́n. (Owe 18:21; Onws 5:3; Jms 3:2.)

20. Ahọn olootọ dabi aayo fadaka: àyà eniyan buburu kò ni iye lori. (Owe 8:19.)

21. Ètè olododo nbọ́ ọpọlọpọ eniyan; ṣugbọn awọn aṣiwere (òmùgọ̀) yoo ku ni àìlọ́gbọ́n. (ẹsẹ 11; Owe 5:23.)

22. Ibukun Oluwa ni nmu ni la, laifi làálàá si i. (Gen 24:35; Psm 37:22.)

---

(10) *(Awọn àdàkọ akọ́kọ́ ti majẹmu laelae lati èdè Heberu si èdè Griki fi ọrọ wọnyií si i.)

**Ìbẹ̀rù Ọlọrun nfunni ni ẹmi gigun.**

23. Bi ohun ẹrẹ ni fun aṣiwere (òmùgọ̀) lati hu ìwà-ìkà: ṣugbọn ìwà ọlọgbọ́n ni inú-dídùn ẹni òye. (Owe 15:21.)

24. Ìbẹ̀ru eniyan buburu nbọwá ba a: ṣugbọn ifẹ olododo ni a o fi fun un. (Psm 145:19; Matt 5:6; 1 Jhn 5:14, 15.)

25. Nigba ti ìjì ba rekọja, eniyan buburu ki yoo si mọ; ṣugbọn olododo ni ìpìlẹ̀ ainipẹkun. (Owe 12:7; Psm 15:5; Matt 7:24; 16:18.)

26. Bi ọti kikan si ehín, ati bi eefin si ojú, bẹẹ ni ọ̀lẹ si ẹni ti o rán an ni iṣẹ́. (Owe 26:6.)

27. Ibẹru Oluwa mu ọjọ gùn: ṣugbọn ọdún eniyan buburu ni a o ṣẹ kuru. (Owe 9:11; Psm 55:23.)

28. Abá olododo ayọ̀ ni yoo jasi: ṣugbọn ireti eniyan buburu ni yoo ṣegbe.

29. Ọ̀nà Oluwa ilu olodi ni fun ẹni iduroṣinṣin, ṣugbọn egbe ni fun awọn oniṣẹ-ẹ̀ṣẹ̀. (Psm 28:8; Owe 21:15.)

30. A ki yoo ṣi olododo ni ipo lae; ṣugbọn eniyan buburu ki yoo gbe ilẹ-ayé. (Psm 37:29.)

31. Ẹnu olootọ mu ọgbọ́n jade; ṣugbọn ahọn àrekérekè ni a o ge kuro.

32. Ètè olododo mọ ohun itẹwọgba; ṣugbọn ẹnu eniyan buburu nsọrọ àrekérekè.

## ORI 11.

**Igberaga ní nṣaaju iparun.**

OṢUWỌN èké irira ni loju Oluwa; ṣugbọn oṣuwọn titọ ni didun inu rẹ̀. (Lef 19:35; Deut 25:13–16.)

2. Bi igberaga bá de, nigba naa ni ìtìjú de, ṣugbọn ọgbọn wà pẹlu onirẹlẹ. (Owe 16:18.)

3. Otitọ aduro-ṣinṣin ni yoo maa tọ́ wọn; ṣugbọn àrekérekè awọn olurekọja ni yoo pa wọn run. (Owe 13:6.)

4. Ọrọ̀ ki i ni anfani ni ọjọ ibinu: ṣugbọn ododo ni igbani lọwọ ikú. (Esk 7:19; Sef 1:18; Gen 7:1.)

5. Ododo ẹni-pipe yoo maa tọ́ ọ̀nà rẹ̀: ṣugbọn eniyan buburu yoo ṣubu ninu ìwà-buburu rẹ̀.

6. Ododo awọn aduro-ṣinṣin yoo gbà wọn là: ṣugbọn awọn olurekọja ni a o mu ninu iṣekuṣe wọn. (Oniws 10:8.)

7. Nigba ti eniyan buburu ba kú, ireti rẹ a dasán, ireti awọn aláìṣedeede eniyan a si dasán. (Owe 10:28.)

8. A yọ olododo kuro ninu iyọnu, eniyan buburu a si bọ si inú rẹ̀. (Owe 21:18.)

9. Ẹnu ni àgàbàgebè nfi pa aladugbo rẹ̀: ṣugbọn ìmọ̀ ni a o fi gba awọn olododo silẹ̀.

10. Nigba ti o ba ndara fun olododo, ìlú a yọ̀: nigba ti eniyan buburu ba ṣegbe, igbe-ayọ̀ a ta. (Owe 28:12.)

11. Nipa ibukun ẹni-iduro-ṣinṣin ìlú a ni igbega: ṣugbọn a bi i ṣubu nipa ẹnu eniyan buburu. (Owe 29:8.)

**Olootọ ọkàn ati olófófó.**

12. Ẹni ti òye kù fun ni ngan ọmọnikeji rẹ̀: ṣugbọn ẹni òye a pa ẹnu rẹ mọ. (Owe 14:21; 10:19.)

13. Ẹni ti nṣe òfófó fi ọ̀ràn ipamọ hàn; ṣugbọn ẹni ti nṣe olootọ-ọkàn a pa ọ̀rọ̀ naa mọ́. (Lef 19:16; Owe 20:19; 1 Tim 5:13; Owe 19:11.)

14. Nibi ti itọni kò si, awọn eniyan a ṣubu; ṣugbọn ninu ọ̀pọ̀ olu gbaninímọ̀ràn ni ailewu wa. (Owe 15:22; 20:18; 24:6.)

15. Ẹni ti o ba ṣe onigbọwọ fun àlejò, ni yoo ri iyọnu; ẹni ti o ba si korira ṣiṣe igbọwọ wà lailewu.

16. Obinrin oloore-ọ̀fẹ́ gba iyì: bi alagbara eniyan ti ngba ọrọ̀. (Owe 31:30.)

17. Alaanu eniyan ṣe rere fun ara rẹ̀: ṣugbọn ìkà-eniyan nyọ ara rẹ lẹnu. (Matt 5:7; 25:34–36.)

18. Eniyan buburu ngba èrè-ẹ̀tàn; ṣugbọn ẹni ti ngbin ododo ni èrè-otitọ wa fun. (Hos 10:12; Gal 6:8,9.)

19. Bi ẹni ti o duro ninu ododo ti nni ìyè, bẹẹ ni ẹni ti nlepa ibi, o nle e si ikú ara rẹ̀.

20. Awọn ti nṣe alárekérekè àyà, irira ni loju Oluwa; ṣugbọn inu rẹ dun si àwọn ẹni-iduro-ṣinṣin. (Owe 12:22; Psm 119:1.)

21. O daju gidigidi pe eniyan buburu ki yoo lọ laijiya, ṣugbọn iru-ọmọ olododo ni a o gbàlà. (Owe 16:5; Psm 112:2.)

22. Bi oruka wura ni imu ẹlẹdẹ, bẹẹ ni arẹwà obinrin ti ko mòye.

23. Kiki rere ni ifẹ inu awọn olododo; ṣugbọn ibinu ni ireti awọn eniyan buburu. (Rom 2:8,9.)

**Eniyan ti o lawọ́, yoo maa ni si i.**

24. Ẹnikan wa ti o lawọ ti si nfunni, sibẹ o nbi si i, ẹnikan si wa ti nháwọ́ jù bi o ti yẹ lọ, ṣugbọn kiki si aini ni. (Owe 13:7; 19:17.)

25. Ọkàn iṣore ni a o mu sanra; ẹni ti o nbomirin ni, ountikararẹ ni a o si bomirin pẹlu. (2 Kor 9:6–10; Matt 5:7.)

26. Ẹni ti o ba dawọ ọkà duro, oun ni eniyan o fibú: ṣugbọn ibukun yoo wa ni ori ẹni ti o ta a. (Amos 8:5,6; Job 29:13.)

27. Ẹni ti o fi ara balẹ wa rere, a ri oju-rere: ṣugbọn ẹni ti o nwa ibi kiri, ibi yoo ba a. (Est 7:10; Psm 7:15; 10:2.)

28. Ẹni ti o ba gbẹkẹle ọrọ̀ rẹ yoo ṣubu: ṣugbọn olododo yoo maa ruwe bi ẹka igi. (Psm 52:7; Mk 10:24; 1 Tim 6:17; Psm 1:3; Jer 17:8.)

29. Ẹni ti o ba yọ ile ara rẹ lẹnu yoo jogun òfo: asiwere (òmùgọ̀) ni yoo maa ṣe iranṣẹ fun ọlọgbọ́n.

30. Eso ododo ni igi iyè; ẹni ti o ba si yi ọ̀kan eniyan pada, ọlọgbọ́n ni. (1 Kro 9:19; Jms 5:20.)

31. Kiye si i a o san an fun olododo ni ayé: melomelo ni eniyan buburu ati ẹlẹ́ṣẹ̀. (Owe 13:21; 2 Sam 22:21,25.)

ORI 12.

**Ẹni ti o fẹ ibawi nfẹ ìmọ̀.**

ENIKẸNI ti o fẹ ẹ̀kọ́, o fẹ ìmọ̀: ṣugbọn ẹni ti o korira ibawi, ẹranko ni. (Owe 9:8; 15:10.)

2. Eniyan rere ni ojurere lọdọ Oluwa; ṣugbọn eniyan elétè buburu ni yoo dalẹbi. (Owe 8:35.)

3. A ki yoo fi ẹsẹ̀ eniyan mulẹ nipa ìwà-buburu: ṣugbọn gbòngbò olododo ki yoo fàtu. (Owe 10:25.)

4. Obinrin oniwa-rere ni adé ọkọ rẹ̀: ṣugbọn eyi ti ndojuti ni dabi ọyún ninu egungun rẹ̀. (Owe 31:23; 1 Kor 11:7; Owe 14:30.)

5. Ìrò olododo tọ́: ṣugbọn ìmọ̀ràn awọn eniyan buburu, ẹ̀tàn ni.

6. Ọ̀rọ̀ eniyan buburu ni lati luba fun ẹ̀jẹ̀: ṣugbọn ẹnu ẹni-iduro-ṣinṣin ni yoo gbà wọn silẹ. (Owe 1:11; 14:3.)

7. A bi eniyan buburu ṣubu, wọn kò si sí: ṣugbọn ile olododo ni yoo duro. (Psm 37:36; Matt 7:24.)

8. A o yin eniyan gẹgẹ bi ọgbọ́n rẹ̀: ṣugbọn ẹni alayidayida àyà ni a o gàn.

9. Ẹni ti a ngàn, ti o si nṣiṣẹ lati bọ ara rẹ̀ o sàn jù ẹni ti nyin ara rẹ̀ ti ko si ni ounjẹ.

10. Olododo eniyan mọ riri ẹ̀mí ẹran (ọ̀sin) rẹ̀: ṣugbọn ìyọ́nú awọn eniyan buburu, ìkà ni. (Deut 25:4.)

11. Ẹni ti o ro ilẹ̀ rẹ̀ ni a o fi ounjẹ tẹlọrun: ṣugbọn ẹni ti ntọ eniyan-lasan lẹhin ni òye kù fun. (Owe 28:19; Ondj 9:4.)

12. Eniyan buburu fẹ ikogun àwọn eniyan buburu: ṣugbọn gbòngbò olododo so èso.

13. Irekọja ètè eniyan buburu ni a fi ndẹkùn mu un: ṣugbọn olododo yoo yọ kuro ninu ìpọ́njú. (Owe 18:7; 2 Pet 2:9.)

14. Nipa èso ọ̀rọ̀ eniyan ni a o fi ohun rere tẹ ẹ lọrun: ẹ̀rè-iṣẹ́ ọwọ́ eniyan ni a o si san fun un. (Owe 13:2; Job 34:11; Isa 3:10,11.)

**Ọlọgbọn ati òmùgọ̀.**

15. Ọ̀na aṣiwere (òmùgọ̀) tọ́ loju ara rẹ̀: ṣugbọn ẹni ti o feti si imọran ni ọlọgbọ́n. (Owe 14:12; Luk 18:11.)

16. Ibinu aṣiwere (òmùgọ̀) kò pẹ lati mọ: ṣugbọn amoye eniyan gbojufo arifin. (Owe 29:11.)

17. Ẹni ti o sọ otitọ, o fi ododo hàn jade; ṣugbọn ẹlẹri èké, sọ ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn. (Owe 14:5.)

18. Àwọn kan nbẹ ti nyara sọ̀rọ̀ lasan bi ìgúnni idà; ṣugbọn ahọ́n ọlọgbọ́n, ilera ni. (Psm 57:4.)

19. Ètè otitọ ni a o mu duro lailae; ṣugbọn ahọn èké, igba diẹ ni. (Psm 52:5.)

20. Ẹ̀tàn wà ni àyà awọn ti nro ibi: ṣugbọn fun awọn ti ngbimọ alaafia, ayọ̀ ni. (ẹsẹ 5.)

21. Ko si ibi kan ti yoo ba olododo; ṣugbọn awọn eniyan buburu ni yoo kun fun ibi. (Psm 91:10; 1 Pet 3:13; Owe 14:14.)

22. Irira loju Oluwa ni ahọ́n èké; ṣugbọn awọn ti nṣe rere ni dídùn-inú rẹ̀. (Owe 6:17; 11:20; Ifh 22:15.)

23. Ọlọgbọ́n eniyan pa ìmọ̀ mọ́; ṣugbọn àyà awọn aṣiwere (òmùgọ̀) nkede ìwà òmùgọ̀ wọn. (Owe 13:16; 15:2.)

24. Ọwọ alaápọn ni yoo ṣe akoso; ṣugbọn ọ̀lẹ ni yoo wà labẹ irú-sínsin

25. Aníyàn pupọ àyà eniyan ni ndori rẹ kodò; ṣugbọn ọ̀rọ̀ rere ni nmu un yọ. (Owe 15:13; Isa 50:4.)

26. Olododo tọ́ aladugbo rẹ̀ si ọ̀nà; ṣugbọn ọ̀nà awọn eniyan buburu tàn wọ́n jẹ.

27. Ọ̀lẹ eniyan ki i le mu ohun ọdẹ rẹ̀; ṣugbọn lati jẹ alaapọn eniyan, ọrọ̀ iyebiye ni.

28. Ni ọ̀nà olododo ni ìyè; ikú ko si loju ọ̀nà otitọ. (Owe 11:19.)

## ORI 13.

**Orisun ọrọ̀ titobi.**

OLỌGBỌ́N ọmọ gba ẹkọ baba rẹ̀; ṣugbọn ẹlẹ́gàn ko gbọ ìbáwí. (Owe 10:1; 15:12.)

2. Eniyan yoo jẹ ohun rere nipa èrè ẹnu rẹ̀; ṣugbọn ifẹ ọkàn awọn olurekọja ni iwa ipa. (Owe 12:14.)

3. Ẹni ti o pa ẹnu rẹ̀ mọ, o pa ẹmi rẹ mọ́; ṣugbọn ẹni ti o ṣi ètè rẹ gbooro yoo ni ipárun. (Psm 39:1; Jak 3:2.)

4. Ọkàn ọ̀lẹ nfẹ, ko si ri nkan; ṣugbọn ọkàn awọn alaapọn ni a o mu sanra. (Owe 10:4.)

5. Olododo korira ẹ̀tàn; ṣugbọn eniyan buburu mu ni hu ìwà irira ati ìtìjú.

6. Ododo pa ẹni-iduro-ṣinṣin ni ọna mọ́; ṣugbọn iwa-buburu ni nmuni ṣubu sínú ẹ̀ṣẹ̀. (Owe 11:3,5.)

7. Ẹnikan wa ti o nṣe bi ọlọ́rọ̀, ṣugbọn ko ni nkan; ẹnikan wa ti o nṣe bi talaka ṣugbọn o ni ọrọ̀ pupọ. (Owe 11:24; Luk 12:20,21,33; 2 Kor 6:10.)

8. Irapada ẹmi eniyan ni ọrọ̀ rẹ̀; ṣugbọn talaka eniyan ko ni ohun irapada.

9. Imọlẹ olododo nfi ayọ̀ tàn; ṣugbọn fitílà eniyan buburu ni a o pa. (Job 18:5; Owe 24:20.)

10. Nipa kiki igberaga ni ìjà ti nwá; ṣugbọn lọdọ awọn ti a fi ìmọ̀ han ni ọgbọn wà. (Owe 11:24.)

11. Ọrọ̀ ti a fi ìwà-asán ni yoo fasẹhin; ṣugbọn ẹni ti o fi iṣẹ́-ọwọ́ kójọ ni yoo maa pọ̀ si i. (Owe 10:2; 14:23.)

**Orisun ìrètí.**

12. Ireti pipẹ nmu ọkàn ṣàìsàn; ṣugbọn ifẹ-ọkàn ti a mu ṣẹ, igi ìyè ni. (ẹsẹ 19.)

13. Ẹnikan ti o ba gàn ọ̀rọ̀ naa ni a o parun: ṣugbọn ẹni ti o bẹ̀ru ofin naa, ni a o san pada fun. (2 Kro 36:16.)

14. Ofin ọlọgbọ́n ni orisun ìyè, lati kuro ninu ìdẹkùn ikú. (Owe 10:11; Psm 18:5.)

15. Ìgbóraẹni-yé mú ojúrere wá; ṣugbọn ọ̀nà awọn ọ̀dàlẹ̀ ṣòro. (Owe 3:4; 21:8.)

16. Gbogbo amoye eniyan ni nfi ìmọ̀ ṣiṣẹ; ṣugbọn aṣiwere (òmùgọ̀) tan ìwà òmùgọ̀ rẹ̀ kalẹ. (Owe 12:23; 15:2.)

17. Oniṣẹ buburu bọ́ sinu ìpọ́njú; ṣugbọn olootọ ikọ̀ mu ilera wa. (Owe 25:13.)

18. Òṣì ati ìtìjú ni fun ẹni ti o kọ ẹ̀kọ́; ṣugbọn ẹni ti o ba fetisi ìbáwí ni a o bu ọlá fun. (Owe 15:5,31,32.)

19. Ifẹ ti a muṣẹ dun mọ ọkàn; ṣugbọn irira ni fun aṣiwere (òmùgọ̀) lati kuro ninu ibi.

20. Ẹni ti o nba ọlọgbọn rin yoo gbọ́n; ṣugbọn ẹgbẹ àwọn aṣiwere (òmùgọ̀) ni yoo ṣègbé. (Owe 15:31; 28:19.)

21. Ibi nlepa awọn ẹlẹ́ṣẹ̀; ṣugbọn fun awọn olododo, rere ni a o maa fi san an. (Psm 32:10.)

22. Eniyan rere fi ogún silẹ fun awọn ọmọ ọmọ rẹ̀; ṣugbọn ọrọ̀ ẹlẹ́ṣẹ̀ ni a tò jọ fun olododo. (Job 27:16,17; Owe 28:8; Onws 2:26.)

23. Ounjẹ pupọ ni o wa ninu ilẹ̀ awọn talaka; ṣugbọn nitori àìlèfoyeṣètò ọ̀pọ̀ rẹ̀ yoo ṣòfò dànù. (Owe 12:11; 14:30–34.)

24. Ẹni ti o ba fa ọwọ́ paṣan sẹ́hìn, o korira ọmọ rẹ̀; ṣugbọn ẹni ti o fẹ ẹ a maa tètè nà án. (Owe 19:18; 22:15; 29:15,17.)

25. Olododo ní àní-tó fun ìtẹ́lọ́rùn ọkàn rẹ̀; ṣugbọn inu awọn eniyan buburu ni yoo ṣe alaini. (Psm 34:10; 37:3.)

ORI 14.

**Ọlọgbọn obinrin ni nkọ́ ile rẹ̀.**

OLUKULUKU ọlọgbọ́n obinrin ni nkọ ilé rẹ̀: ṣugbọn aṣiwere (òmùgọ̀) a fi ọwọ́ ara rẹ̀ fa a lulẹ̀. (Owe 24:3.)

2. Ẹni ti o nrin ni iduro-ṣinṣin rẹ̀ o bẹ̀ru Oluwa: ṣugbọn ẹni ti o ṣe àrekérekè ni ọ̀nà rẹ̀, o gàn án. (Owe 19:1; Rom 2:4.)

3. Ni ẹnu aṣiwere (òmùgọ̀) ni pàṣán igberaga; ṣugbọn ètè awọn ọlọgbọ́n ni yoo pa wọn mọ́. (Owe 12:6.)

4. Nibi ti malu kò sí, ibujẹ a di ofo: ṣugbọn ibisi pupọ nbẹ nipa agbara malu.

5. Ẹlẹri olootọ ko jẹ ṣèké: ṣugbọn ètàn ni ẹlẹri èké maa nsọ jade. (Eks 20:16; Owe 6:19; 12:17.)

6. Ẹlẹgan nwa ọgbọ́n, ko si ri i: ṣugbọn ìmọ̀ ko ṣoro fun ẹni ti òye yé. (Owe 24:7; 8:9; 17:24.)

7. Kuro niwaju aṣiwere (òmùgọ̀), ati lọdọ ẹni ti ko ni ètè ìmọ̀.

8. Ọgbọ́n amòye ni lati mòye ọ̀nà rẹ̀: ṣugbọn ìwà òmùgọ̀ awọn aṣiwere (òmùgọ̀) ni ẹ̀tàn.

9. Awọn aṣiwere (òmùgọ̀) nfi ẹbi-ẹ̀ṣẹ̀ ṣẹ̀sín: ṣugbọn ojurere wa laarin awọn olódodo.

10. Àyà mọ ikorò ara rẹ̀; ko si alejo kan tii ṣe alábapin ayọ̀ rẹ̀.

11. Ilé eniyan buburu ni a o run: ṣugbọn agọ ẹni-iduro-ṣinṣin ni yoo maa gbilẹ̀. (Owe 3:33; 12:7; 15:25.)

12. Ọ̀nà kan wa ti o dabi ẹni pe o dara loju eniyan, ṣugbọn opin rẹ̀ ọ̀nà ikú ni. (Owe 16:25; Rom 6:21.)

13. Ninu ẹ̀rín pẹlu, àyà a maa kaanu; ati opin ayọ ni ibanujẹ. (Owe 5:4; Onws 2:2.)

14. **Alápèhìndà eniyan ni a o fi èso ọ̀nà ara rẹ̀ kún: ṣugbọn eniyan rere yoo ni ìtẹ́lọ́rùn ninu ọkan rẹ̀.** (Owe 1:31; 12:14.)

15. Òpè eniyan gba ọ̀rọ̀ gbogbo gbọ́: ṣugbọn amoye eniyan wo ọ̀nà ara rẹ̀ daradara.

16. Ọlọgbọ́n eniyan bẹru, o si kuro ninu ibi; ṣugbọn aṣiwere (òmùgọ̀) gberaga, o si da ara rẹ̀ loju. (Owe 22:3.)

17. Ẹni ti o ba tete binu, huwa omugọ; ẹni eléte buburu ni a korira. (ẹsẹ 29.)

18. Awọn òpè jogun ìwà òmùgọ̀; ṣugbọn awọn amoye ni a fi ìmọ̀ dé ni adé. (Owe 18:15.)

19. Awọn ẹni-buburu, tẹriba niwaju awọn ẹnirere; ati awọn eniyan buburu ni ẹnu-ọ̀nà awọn olododo. (Owe 11:29.)

**Ọlọ́rọ̀ ati tálákà.**

20. A tilẹ korira tálákà lati ọdọ aladugbo rẹ̀ wa: ṣugbọn ọlọ́rọ̀ ni ọ̀rẹ́ púpọ̀. (Owe 19:7.)

21. Ẹni ti o kẹ́gàn ẹnikeji rẹ̀, o ṣẹ̀: ṣugbọn ẹni ti o ba ṣaanu fun awọn tálákà, ibukun ni fun un. (Owe 11:12; Psm 41:1.)

22. Awọn ti ngbimọ̀ buburu ko ha

şina bi? Şugbọn aanu ati otitọ ni fun awọn ti ngbimọ ire.

23. Ninu gbogbo làálàá ni ere pupọ wa: şugbọn ọ̀rọ̀-ẹnu lásán kò ni ohun kan.

24. Adé awọn ọlọgbọ́n ni ọgbọ́n wọn: şugbọn ìwà-àìmọ̀ye awọn ọ̀mùgọ̀ ni wèrè wọn.

25. Olootọ ẹlẹri ngbà ọkàn silẹ: şugbọn ẹlẹri ẹ̀tàn sọ̀rọ̀ èké. (ẹsẹ 5.)

26. Ninu ibẹ̀ru Oluwa ni igbẹkẹle ti o lagbara: awọn ọmọ rẹ̀ yoo si ri ibi àbò. (Owe 19:23; Isa 33:6.)

27. Ibẹ̀ru Oluwa ni orisun ìyè, lati kuro ninu ìkẹkùn ikú. (Owe 13:14.)

28. Ninu ọ̀pọ̀ eniyan ni Ọba ni iyì; şugbọn laisi eniyan ọmọ-alade yoo parun.

29. Ẹni ti o ba lọ́ra lati binu, o ni ìmọ̀ pupọ; şugbọn ẹni ti o ba yara binu o fi ìwà-ọ̀mùgọ̀ rẹ̀ hàn. (Owe 16:32; Jak 1:19; Owe 29:20.)

30. Àyà ti o yè kooro ni ìyè ara; şugbọn ilara ni ìbàjẹ́ egungun. (Owe 12:4.)

31. Ẹni ti o ba nni tálákà lara, o gàn Ẹlẹda rẹ̀; şugbọn ẹni ti o şaanu fun tálákà o bu ọlá fun un. (Owe 17:5; ẹsẹ 21.)

32. Eniyan buburu ni a npa run ninu ìwà-buburu rẹ̀; şugbọn olododo ní ireti ninu ikú rẹ̀. (Job 13:15; Psm 23:4; 2 Kor 1:9; 2 Tim 4:18.)

33. Ọgbọ́n fi idi kalẹ ni àyà ẹni ti o mòye; şugbọn a fi i han láyà awọn aşiwèrè (ọ̀mùgọ̀). (Owe 2:10; 12:16.)

34. Ododo ni ngbe orilẹ-èdè lékè; şugbọn ẹ̀şẹ̀ ni ẹ̀gàn orilẹ-èdè. (Owe 11:11.)

35. Ojurere ọba nbẹ ni ọdọ ọlọgbọ́n iranşẹ; şugbọn ibinu rẹ̀ si iranşẹ ti nhuwa ìtìjú. (Matt 24:45.)

ORI 15.

**Ahọ́n ọlọgbọ́n eniyan.**

IDAHUN pẹlẹ yí ìbínú pada; şugbọn ọ̀rọ̀ líle ni nru ìbínú sókè. (Ondj 8:1–3; 1 Sam 25:10–13.)

2. Ahọn ọlọgbọ́n nlo ìmọ̀ rere: şugbọn ẹnu aşiwere (ọ̀mùgọ̀) a maa gufẹ ìwà-wèrè. (Owe 12:23; 13:16.)

3. Oju Oluwa nbẹ ni ibi gbogbo, o nwo àwọn ẹni-buburu ati ẹni-rere. (Job 34:21; Heb 4:13.)

4. Ahọn imularada ni igi ìyè: şugbọn àyídáyidà ninu rẹ̀ ni ibajẹ ọkàn.

5. Aşiwere (ọ̀mùgọ̀) gan ẹ̀kọ́ baba rẹ̀: şugbọn ẹni ti o ba feti si ibawi ni o mòye. (Owe 13:1,18.)

6. Ni ilé olododo ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ işura: şugbọn ninu èrè eniyan buburu ni ìyọnu.

7. Ètè ọlọgbọ́n tan ìmọ̀ kalẹ: şugbọn ayé aşiwere (ọ̀mùgọ̀) ki i şe bẹẹ.

8. Ẹbọ awọn eniyan buburu, irira ni loju Oluwa; şugbọn adura awọn ẹni-iduroşinşin ni dídùn-inú rẹ̀. (Isa 1:11; Jer 6:20; Mika 6:7.)

9. Ọna eniyan buburu, irira ni loju Oluwa; şugbọn ó fẹ́ ẹni ti ntọ ododo lẹ́hìn. (Owe 21:21; 1 Tim 6:11.)

10. Ìkìlọ̀ kikan wa fun ẹni ti o kọ ọ̀nà sílẹ̀; ẹni ti o ba si korira ibawi yoo kú. (Owe 1:29–32; 5:12.)

11. Isà-òkú ati iparun şi sílẹ̀ niwaju Oluwa; melomelo ni àyà awọn ọmọ eniyan. (Job 26:6; Psm 139:8; 2 Kro 6:30.)

12. Ẹlẹ́gàn kò fẹ ẹni ti nba a wi; bẹẹ ni ki yoo tọ awọn ọlọgbọ́n lọ. (Owe 13:1; Amos 5:10.)

**Èrè inu-didun.**

13. Inu-dídùn a mu oju darayá; şugbọn nipa ibanujẹ àyà, ọkàn a rẹ̀wẹ̀sì. (Owe 17:22; 12:25.)

14. Aya ẹni ti oye yé nşe afẹri ìmọ̀; şugbọn ẹnu aşiwere (ọ̀mùgọ̀) nfi ìwàwèrè bọ́ ara rẹ̀.

15. Gbogbo ọjọ́ olùpọ́njú ni ibi; şugbọn onínú-dídùn njẹ alaafia nigbagbogbo. (ẹsẹ 13.)

16. Diẹ pẹlu ibẹru Oluwa, o san ju işura pupọ pẹlu ìyọnu ninu rẹ̀. (Psm 37:16; Owe 16:8; 1 Tim 6:6.)

17. Ounjẹ ewébẹ̀ nibi ti ifẹ wà, o san ju abọ́pa malu lọ oun pẹlu irira. (Owe 17:1.)

18. Abínú eniyan ru asọ sókè; ṣugbọn ẹni ti o lọra lati binu, o tu ìjà ninu. (Owe 26:21; 29:22; 14:29.)

19. Ọnà ọlẹ dabi igbó ẹgún; ṣugbọn ọnà olododo ọnà ti o tẹjú ni. (Owe 22:5.)

20. Ọlọgbọ́n ọmọ ṣe baba aláyọ̀; ṣugbọn aṣiwere (òmùgọ̀) eniyan gan ìyá rẹ̀. (Owe 10:1; 30:17.)

**Ẹkọ́ ọgbọ́n.**

21. Ayọ ni ìwà-wèrè fun ẹni ti òye kù fun; ṣugbọn ẹni-òye a maa rin ni ìdúró-ṣinṣin. (Owe 10:23; Ef 5:15.)

22. Laisi amọran, èrò a dasan; ṣugbọn ni ọpọlọpọ olugbimọ, wọn a fi ìdí mulẹ. (Owe 11:14; 20:18.)

23. Eniyan ni ayọ nipa idahun ẹnu rẹ̀; ati pe ọ̀rọ̀ kan ti o sọ jade ni akoko rẹ̀, o ti dara tó! (Owe 25:11.)

24. Ọnà ọlọgbọ́n lọ sókè si ìyè, ki o le yẹra fun isà-òkú nisalẹ. (Owe 4:18.)

25. Oluwa yoo run ilé agberaga; ṣugbọn yoo fi ààlà ilẹ òpó mulẹ. (Owe 12:7; Psm 68:5,6.)

26. Iro inu eniyan buburu, irira ni loju Oluwa; ṣugbọn ọ̀rọ̀ ẹni-mimọ ni ọ̀rọ̀ dídùn niwaju rẹ̀. (Owe 6:16–19; 16:24.)

27. Ẹni ti o njẹ èrè aiṣododo, o nyọ ilé ara rẹ̀ lẹnu; ṣugbọn ẹni ti o korira ẹ̀bùn yoo yè. (Owe 28:25; 1 Tim 6:10; Isa 33:15.)

28. Àyà olododo ṣe àṣàrò lati dahun; ṣugbọn ẹnu eniyan buburu ngúfẹ ohun ibi jade. (1 Pet 3:15.)

29. Oluwa jinna si awọn eniyan-buburu; ṣugbọn o gbọ adura awọn olododo. (Psm 34:16; 145:18.)

30. Imọlẹ oju mu inu dùn; ìhìn rere si mu egungun sanra.

31. Ẹni ti o ba gbọ́ ìbáwí ìyè, a jokòó laarin awọn ọlọgbọ́n. (ẹsẹ 5.)

32. Ẹni ti o kọ ẹ̀kọ́, o gan ọkàn ara rẹ̀: ṣugbọn ẹni ti o ba gbọ́ ìbáwí, o ni ìmòye. (Owe 1:7; 8:36; 15:5.)

33. Ibẹru Oluwa ni ẹ̀kó ọgbọ́n: ati ṣaaju ọlá ni ìrẹ̀lẹ̀. (Owe 1:7; 18:12.)

## ORI 16.

**Gbogbo ọ̀nà eniyan ni o dara ni ojú rẹ̀.**

IMURA àyà, ti eniyan ni, ṣugbọn lati ọ̀dọ̀ Oluwa ni idahun ahọ́n. (Owe 19:21.)

2. Gbogbo ọ̀nà eniyan ni o mọ́ lójú ara rẹ̀; ṣugbọn Oluwa ni o ndiwọn ọkàn. (Owe 21:2.)

3. Ka iṣẹ́ rẹ le Oluwa lọwọ, a o si fi idi iro-inu rẹ kalẹ̀. (Psm 37:5.)

4. Oluwa ti ṣe ohun gbogbo fun ipinnu rẹ̀: nitootọ, awọn eniyan buburu fun ọjọ́ ibi. (Isa 43:7; Job 21:30.)

5. Olukuluku eniyan ti o gberaga ni àyà, ìrira ni loju Oluwa: o daju pé, ki yoo lọ láìjìyà. (Owe 6:17; 11:21.)

6. Nipa aanu ati otitọ a bo ẹ̀ṣẹ̀ mọ́lẹ̀; ati nipa ibẹru Oluwa, eniyan a kuro ninu ibi. (Dan 4:27; Owe 14:16.)

7. Nigba ti ọ̀nà eniyan ba wu Oluwa, Oun a mu awọn ọ̀tá rẹ̀ paapaa wa pẹlu rẹ̀ ni alaafia. (2 Kro 17:10.)

8. Diẹ pẹlu ododo, o san jù ọrọ nla lọ laisi ẹ̀tọ́. (Owe 15:16.)

9. Àyà eniyan ni npinnu ọ̀nà rẹ̀, ṣugbọn Oluwa ni o ntọ́ iṣisẹ rẹ̀. (Psm 37:23; Owe 20:24; Jer 10:23.)

10. Ọ̀rọ̀ ìmísí nbẹ ni ètè ọba: ẹnu rẹ̀ ki i ṣẹ̀ ni idajọ.

11. Ìwọ̀n ati òṣùwọ̀n titọ ni ti Oluwa: gbogbo okuta-iwọ̀n ti nbẹ ninu àpò, iṣẹ́ rẹ̀ ni. (Owe 11:1.)

**Ogbọ́n ni orisun ìyè.**

12. Ìrira ni fun awọn ọba lati ṣe buburu: nitori pe nipa ododo ni a ti fi idi ìtẹ́ kalẹ̀. (Owe 25:5.)

13. Ètè ododo ni dídùn-inú awọn ọba: wọn si fẹ ẹni ti nsọrọ titọ. (Owe 14:35.)

14. Ibinu ọba dabi iranṣẹ ikú: ṣugbọn ọlọgbọ́n eniyan ni yoo tù ú. (Owe 19:12.)

15. Ninu ìmọ́lẹ̀ oju ọba ni ìyè; ojurere rẹ̀ si dabi ikuukuu awọsanma ti nmu òjò àrọ̀kúrò wa. (Job 29:23.)

16. Lati ni ọgbọ́n, melomelo ni o san ju wúrà lọ; ati lati ni òye, melo-

melo ni o dara ju fàdákà lọ. (Owe 8:10,19.)

17. Òpópó-ọ̀nà awọn ẹni-iduro-ṣinṣin yà kúrò ninu ibi: ẹni ti o pa ọ̀nà rẹ̀ mọ́, o pa ọkàn rẹ̀ mọ́.

18. Igberaga ni nṣaaju iparun, agídí ọkàn ni nṣaaju ìṣubú. (Owe 11:2.)

19. O san lati ṣe onirẹlẹ ọkàn pẹlu awọn tálákà, jù lati ba awọn agberaga pin ìkógun.

20. Ẹni ti o fi òye gba ọ̀rọ̀ yoo ri ire; ẹni ti o si gbẹkẹ le Oluwa, ibukun ni fun un. (O.D. 2:12; 34:8; Jer 17:7.)

21. Ọlọgbọ́n àyà ni a o pe ni amòye: didun-ètè a si maa mu ẹ̀kọ́ pọ̀.

22. Òye ni orisun ìyè fun ẹni ti o ni i: ṣugbọn ẹ̀kọ́ aṣiwere (òmùgọ̀) ni ìwà-wèrè. (Owe 13:14; 7:22.)

23. Àyà ọlọgbọ́n mu ọ̀rọ̀ ẹnu rẹ̀ jade pẹlu ìwárìrì, o si mu ẹ̀kọ́ pọ létè rẹ̀. (Owe 37:30.)

24. Ọ̀rọ̀ dídùn dabi afárá-oyin, o dun mọ ọkàn, o si ṣe ilera fun egungun.

**Ọ̀nà buburu eniyan dara ni ojú rẹ̀.**

25. Ọ̀nà kan wa ti o dabi ẹni pé o dara fun eniyan, ṣugbọn òpin rẹ̀ ni ọ̀nà ikú. (Owe 14:12.)

26. Okàn ti o nṣiṣẹ, o nṣiṣẹ fun ara rẹ̀; nitori pé ẹnu ara rẹ̀ ni o nsun un ṣe e.

27. Eniyan-buburu hu ìwà-ibi jade, ati ni ètè rẹ̀ bi ẹni pe iná jíjó ni o wa nibẹ. (Owe 6:12; 14:18; Jak 3:6.)

28. Aláyídáyidà eniyan dá ìjà sílẹ̀: asọ̀rọ̀kẹ́lẹ́ ya awọn ọ̀rẹ́ ni ipa. (Owe 15:18; 17:9.)

29. Ẹni ìwà-ipá tan aladugbo rẹ̀, a si mu un lọ si ipa-ọ̀nà ti kò dara. (Owe 1:10.)

30. Ẹni ti o nṣẹ́ oju rẹ̀ pépé ngbèrò ohun àyídáyidà; ẹni ti o sì ṣu ẹnu pọ̀ yoo mu ki ohun buburu ṣẹlẹ̀.

31. Adé ògo ni ori ewú, bi a ba ri i ni ọ̀nà ododo. (Owe 20:29.)

32. Ẹni ti o lọ́ra lati binu, o san ju alagbara lọ; ẹni ti o si ṣe akoso ẹmi rẹ̀, o ju ẹni ti o ṣẹgun ìlú lọ. (Owe 19:11.)

33. A ṣẹ́ gègé dà si iṣẹpo aṣọ; ṣugbọn gbogbo idajọ rẹ̀ lọwọ Oluwa ni.

## ORI 17.

**Ọ̀rọ̀ rere ati ọ̀rọ̀ asán.**

OKÈLÈ gbigbẹ, pẹlu alaafia, o san ju ilé ti o kún fun ẹran-pipa pẹlu ìjà. (Owe 15:17.)

2. Ọlọgbọ́n iranṣẹ yoo ṣe olori ọmọ ti nhuwa ìtìjú, yoo si pin ogún laarin awọn arakunrin. (Owe 10:5.)

3. Ìkòkò ni fun fàdákà, ati ileru fun wúrà: bẹẹ ni Oluwa ndan àyà wo. (Owe 27:21; Psm 26:2.)

4. Oluṣe buburu fetisi ètè èké; ẹni-èké a si maa kiyesi ọ̀rọ̀ ahọ́n, buburu.

5. Ẹnikẹni ti o ba sín tálákà jẹ, o gan Ẹlẹ́da rẹ̀: ẹni ti o ba si nyọ̀ si wahala ki yoo wà ni àìjìyà. (Owe 14:31; Job 31:29.)

6. Ọmọ-ọmọ ni adé arúgbó: ògo awọn ọmọ sì ni baba wọn. (Owe 13:22.)

7. Ọ̀rọ̀ daradara kò yẹ fun aṣiwere (òmùgọ̀); bẹẹ ni ètè èké ko yẹ fun ọmọ alade.

8. Owó-àbẹ̀tẹ́lẹ̀ dabi okuta iyebíye loju ẹni ti o funni; nibikibi ti o yi si, ni o nṣe rere. (Owe 21:14; Isa 1:23; Amos 5:12.)

9. Ẹni ti o bo ọ̀ràn mọlẹ, o nwa ìfẹ́; ṣugbọn ẹni ti o tun hú ọ̀ràn síta, o ya ọ̀rẹ́ nipa. (Owe 10:12; Jak 5:20; 1 Pet 4:8; Owe 16:28.)

10. Ọrọ-ìbáwí dun ọlọ́gbọ́n de inu ọkan ju ọgọrun pàṣán lara aṣiwèrè (òmùgọ̀) lọ.

11. Ẹni-ọ̀tẹ̀ a maa wá kìkì ibi kiri; nitori naa iranṣẹ ìkà ni a o ran si i.

12. Ó sàn ki abo-beari ti a kọ́ ni ọmọ o pade eniyan, ju aṣiwere (òmùgọ̀) lọ ninu ìwà-wèrè rẹ̀. (Hos 13:8.)

**Ọgbọ́n níye lori.**

13. Ẹnikẹni ti o ba fi ibi san ire, ibi ki yoo kuro ninu ilé rẹ̀. (Psm 109:4,5; Jer 18:20.)

14. Ipilẹṣẹ ìjà dabi títú omi jade; nitori naa fi ìjà silẹ ki o to di nla. (Owe 20:3.)

15. Ẹni ti o dá eniyan buburu lare, ati ẹni ti o da olododo lẹbi, ani awọn mejeji ìríra ni loju Oluwa. (Eks 23:7; Isa 5:23.)

16. Nitori kinni iye owó yoo ṣe wa lọwọ aṣiwere (òmùgọ̀) lati ra ọgbọ́n, nigba ti ko ni òye?

17. Ọrẹ́ a maa fẹni nigbagbogbo, ṣugbọn arakunrin ni a bi fun ìgbà ìpọ́njú. (Rut 1:16; Owe 18:24.)

18. Eniyan ti oye kù fun, a ṣe onigbọ̀wọ́, a si fi ara sọfa niwaju ọ̀rẹ́ rẹ̀. (Owe 6:1.)

19. Ẹni ti o fẹ ìjà, o fẹ ẹ̀ṣẹ̀; ẹni ti o kọ́ ẹnu-ọ̀nà rẹ̀ ga, o nwa ìparun. (Owe 29:22; 16:18.)

20. Ẹni ti o ni àyídáyidà ọkàn ki yoo ri ire: ati ẹni ti o ni ahọ́n ọ̀rọ-meji, a bọ sinu ibi. (Jak 3:8.)

21. Aṣiwèrè (òmùgọ̀) ọmọ jẹ ibanujẹ baba rẹ; baba aṣiwère (òmùgọ̀) kò ni ayọ̀. (Owe 10:1; 19:13.)

22. Inú-dídùn mu imularada rere wá: ṣugbọn ibanujẹ ọkàn mu egungun gbẹ. (Owe 15:13; Psm 22:15.)

23. Eniyan buburu gba owó-àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lati ibi-ìkọ̀kọ̀ lati yi ọ̀nà idajọ pada. (Eks 23:8.)

24. Ọgbọ́n wà niwaju ẹni ti o mòye; ṣugbọn ojú aṣiwere (òmùgọ̀) nbẹ ni òpin ilẹ̀-ayé. (Onws 2:14.)

25. Aṣiwere (òmùgọ̀) ọmọ ni ibanujẹ baba rẹ̀, ati kikoro ọkàn fun ìyá ti o bi i. (Owe 10:1.)

26. Pẹlupẹlu ko dara ki a jẹ olotitọ ni ìyà, tabi ki a lu awọn ọmọ-alade nitori ṣègbè wọn. (Owe 18:5.)

27. Ẹni ti o ni ìmọ̀, a ṣẹ́ ọ̀rọ̀ rẹ kù: ọlọkan tútù si ni amòye eniyan.(Jms 1:19.)

28. Lootọ, aṣiwere (òmùgọ̀); nigba ti o ba pa ẹnu rẹ̀ mọ, a o ka a si ọlọgbọ́n, nigba ti o ba si pa ẹnu rẹ̀ mọ́ a o ka a si amòye. (Job 13:5.)

## ORI 18.

**Ọ̀rọ̀ ọlọgbọ́n ati ti òmùgọ̀.**

ẸNI ti o ya ara rẹ sọ́tọ̀ yoo lepa ìfẹ́ ara rẹ̀, yoo si kọjú ìjà nla si ohunkohun ti i ṣe ti òye.

2. Aṣiwere (òmùgọ̀) ko ni inú-dídùn si ìmòye, bi ko ṣe ki o le fi èrò-ọkàn ara rẹ̀ hàn. (Owe 12:23.)

3. Nigba ti eniyan-buburu ba dé, nigba naa ni ẹ̀gàn dé, ati pẹlu ẹ̀gàn ni ìtìjú.

4. Ọ̀rọ̀ ẹnu eniyan dabi omi jinjin, orisun ọgbọ́n bi odò ṣiṣàn. (Owe 20:5; 10:11.)

5. Kò dara lati ṣe ojuṣaju eniyan-buburu, lati bi olododo ṣubú ni idajọ. (Lef 19:15; Deut 1:17; Owe 24:23.)

6. Ètè aṣiwere (òmùgọ̀) ni nmu ìjà wa, ẹnu rẹ̀ a si maa fa ina wá.

7. Ẹnu aṣiwere (òmùgọ̀) ni iparun rẹ̀, ètè rẹ̀ si ni ikẹkun ọkan rẹ̀. (Owe 10:14; Onws 10:12.)

8. Ọ̀rọ̀ olófofó dabi àdídùn, wọn a si wọ isalẹ inu lọ. (Owe 26:22.)

9. Ẹni ti o lọra ni idi iṣẹ́ rẹ̀, arakunrin ni sí jẹgúdújẹrá eniyan. (Owe 28:24.)

10. Orukọ Oluwa, ilé-ìṣọ́ agbara ni: Olododo sa wọ inu rẹ̀, o si là. (2 Sam 22:3; Psm 18:2.)

11. Ọrọ̀ ọlọ́rọ̀ ni ilu-agbara rẹ̀, o si dabi odi gíga ni ojú ara rẹ̀. (Owe 10:15.)

12. Ṣaaju ìparun, àyà eniyan a ṣe agídí, ṣaaju ọlá si ni ìrẹ̀lẹ̀. (Owe 11:2.)

13. Ẹni ti o ba dahun ọ̀rọ̀ ki o to gbọ́, ìwà-wèrè ati ìtìjú ni fun un. (Jhn 7:51.)

14. Ọkàn eniyan yoo fàyàrán àìlera rẹ̀; ṣugbọn ọkàn ti o rẹ̀wẹ̀sì, tani yoo gbà á?

15. Àyà amòye ngba ìmọ̀; eti ọlọgbọ́n a si maa ṣe afẹri ìmọ̀.

16. Ọrẹ́ eniyan a maa fi àyè fún un, a si mú un wá siwaju awọn eniyan nla. (Gen 32:20; 1 Sam 25:27.)

17. Ẹnikini ninu ẹjọ́ rẹ̀ a dabi ẹni pe ó jàre, titi ẹnikeji rẹ̀ yoo fi de lati hudi rẹ̀ sita.

18. Gègé mu àríyànjiyàn parí, a si làjà laarin awọn alágbára. (Owe 16:33.)

19. Arakunrin ti a ṣe arekérekè sí ju ilú-olódi alágbára lọ; bẹẹ ni ìjà dàbí ọ̀pá idabùú ààfin. (Ef 4:3; Filp 4:16,18; 1 Kor 1:11-13; Psm 119:78;133:1.)

20. Ọrọ̀ ẹnu eniyan a maa mu inu rẹ̀ tutù: ibisi ẹnu rẹ̀ ni a o si fi tu u ninu. (Owe 12:14.)

21. Ikú ati ìyè wa ninu agbára ahọ́n; awọn ti o fẹ ẹ yoo jẹ èso rẹ̀. (Matt 12:37.)

22. Ẹnikẹni ti o ri aya fẹ, o ri ohun rere, o si ri ojurere lọdọ Oluwa. (Owe 19:14; 8:35.)

23. Táláká a maa bẹ ẹ̀bẹ̀; ṣugbọn ọlọ́rọ̀ a maa fi ikanra dahun. (Jms 2:3.)

24. Ẹni ti o ni ọ̀rẹ́ pupọ, o ṣe e si ìparun ara rẹ̀; ọ̀rẹ́ kan si nbẹ ti o fi ara mọni ju arakunrin lọ. (Owe 17:17.)

## ORÍ 19.

**Ifiwera ọrọ̀ ati òṣì.**

TÁLÁKÀ ti nrin ninu ìwà-títọ́ rẹ̀, o sàn ju ẹni ti o nṣe àrekérekè ni ètè rẹ̀ lọ, òmùgọ̀ si ni pẹlú. (Owe 28:6.)

2. Pẹlupẹlu, ọkàn láìní ìmọ̀, ko dara; ẹni ti o ba si fi ẹsẹ̀ rẹ̀ yara yoo ṣubú.

3. Nigba ti ìwà-òmùgọ̀ eniyan ba mu ìparun ba ọ̀nà ara rẹ̀, ọkàn rẹ̀ a gbóná ni ìbínú si Oluwa. (Owe 11:3; Psm 37:7.)

4. Ọrọ̀ fa ọ̀rẹ́ pupọ; ṣugbọn táláká ni ọ̀rẹ́ rẹ̀ nyẹra fun. (Owe 14:20; ẹsẹ 7.)

5. Ẹlẹri èké ki yoo lọ láìjìyà, ati ẹni ti o si nṣèké ki yoo mu u jẹ. (Eks 23:1; Owe 6:19.)

6. Ọpọlọpọ ni yoo maa bẹ̀bẹ̀ ojurere ọmọ-aládé: olukuluku eniyan ni nṣe ọ̀rẹ́ ẹni ti ntani lọ́rẹ.

7. Gbogbo awọn arakunrin táláká ni nkorira rẹ̀: melomelo ni awọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ yoo ha jinna si i? O nfi ọ̀rọ̀ tẹle wọn, ṣugbọn wọn jìnà sii. (ẹsẹ 4; Psm 38:11.)

8. Ẹni ti o gbọ́n, o fẹ́ ọkàn rẹ̀: ẹni ti o pa òye mọ́ yoo ri rere. (Owe 16:20.)

9. Ẹlẹri èké ki yoo lọ láìjìyà, ẹni ti o si nṣeke yoo ṣègbé. (ẹsẹ 5.)

10. Ohun rere kò yẹ fún aṣiwere (òmùgọ̀); ámbọ̀sì-bọ́sí fun ẹrú lati ṣe olori awọn ìjòyè. (Onws 10:6,7.)

11. Ìmòye eniyan mu un lọ́ra lati bínú; ogo rẹ̀ sì ni lati ré ẹ̀ṣẹ̀ kọjá. (Jms 1:19; Owe 16:32.)

12. Ìbínú ọba dabi igbe kìnnìún; ṣugbọn ojurere rẹ̀ dabi ìrì lara koríko. (Owe 16:14; Hos 14:5.)

13. Aṣiwere (òmùgọ̀) ọmọ ni ìbànújẹ́ baba rẹ̀: oníjọ̀gbọ̀n ìyàwó dabi ọ̀ṣọ̀rọ̀ òjò. (Owe 10:1; 21:9.)

14. Ilé ati ọrọ̀ ni ogún awọn baba: ṣugbọn amòye aya, lati ọdọ Oluwa wá ni. (2 Kor 12:14; Owe 18:22.)

15. Ìmẹ́lẹ́ mu ni sùn oorun fọnfọn; ọkàn ọlẹ ni ebi yoo si pa. (Owe 6:9; 10:4.)

16. Ẹni ti o pa ofin mọ́, ó pa ọkàn ara rẹ̀ mọ́; ṣugbọn ẹni ti o ba kẹgàn ọ̀nà rẹ̀ yoo ku. (Luk 10:28.)

17. Ẹni ti o ṣaanu fun táláká Oluwa ni o wín; yoo san iṣeun rẹ̀ pada fun un. (Onws 11:1; Matt 10:42; 2 Kor 9:6–8; Heb 6:10.)

**Ìmọ̀ràn ati ẹ̀kọ́.**

18. Na ọmọ rẹ nigba ti ireti wà, má si ṣe gbe ọkan rẹ lé iparun rẹ̀. (Owe 13:24.)

19. Onibinu nla ni yoo jìyà; nitori pe bi iwọ ba gba a silẹ, sibẹ iwọ o tun ṣe e lẹkan si i.

20. Feti si ìmọ̀ ki o si gba ẹ̀kọ́, ki o le gbọ́n ni igbẹhin rẹ̀. (Owe 8:33.)

21. Ète pupọ ni o wa ni àyà eniyan; ṣugbọn ipinnu Oluwa, oun ni yoo dúró. (Owe 16:1,9; Psm 33:10,11.)

22. Ohun ti a nwa lara eniyan ni ìwà-iṣootọ rẹ̀: talaka eniyan si sàn ju elékèé o.

23. Ìbẹ̀rù Oluwa tẹ si ìyè: ẹni ti o ni i yoo jokòó ni itẹlọrun; a ki yoo fi ibi bẹ̀ ẹ́ wò. (1 Tim 4:8; Psm 25:13; Owe 12:21.)

24. Ìmẹ́lẹ́ eniyan ki ọwọ́ rẹ sinu ìṣásùn, ko si le yọ ọ jade pada wa si ẹnu ara rẹ̀. (Owe 26:15.)

25. Lu ẹlẹ́gàn, òpè yoo si kiyesara: Si ba ẹni ti o mòye wí, òye ìmọ̀ yoo si ye e. (Owe 21:11; 9:8.)

26. Ẹni ti o ba nṣika si baba rẹ̀, ti o si lé ìyá rẹ̀ jade, oun ni ọmọ ti nṣe ìtìjú, ti o si mu ẹ̀gàn wá. (Owe 28:24; 17:2.)

27. Ọmọ mi, dẹ́kun lati feti si ẹ̀kọ́ ti nmu ni ṣìnà kuro nínú ọ̀rọ̀ ìmọ̀.

28. Ẹlẹri buburu fi idajọ ṣẹ̀sín: ẹnu eniyan buburu, si ngbe aiṣedeede mì. (Job 15:16.)

29. A pèsè ọ̀rọ-idajọ fun awọn ẹlẹ́gàn, ati pàṣán fun ẹ̀hìn awọn aṣiwẹ̀rè (ọ̀mùgọ̀). (Owe 10:13; 26:3.)

## ORI 20.

**Otitọ inu olododo.**

ELẸ́YÀ ni ọti-waini, aláriwo ni ọti lile, ẹnikẹni ti a bá fi tànjẹ kò gbọ́n. (Gen 9:21; Isa 5:22.)

2. Ìbẹ̀rù ọba dabi igbe kinniun: ẹnikẹni ti o ba mu un binu, ó ṣẹ̀ si ọkàn ara rẹ̀. (Owe 19:12; 8:36; 1 A.Ọba 2:23.)

3. Ọlá ni fun eniyan lati ṣíwọ́ kuro ninu ìjà: ṣugbọn olukuluku aṣiwère (omugọ) ni o maa nja ìjà nla. (Owe 17:14.)

4. Ọlẹ kò jẹ tu ilẹ ni igba òtútù; nitori naa ni yoo fi maa ṣagbe nigba ikore, ki yoo si ni nkan. (Owe 10:4; 19:15,24.)

5. Ìmọ̀ ninu ọkàn eniyan dabi omi jínjìn; ṣugbọn amòye eniyan ni nfa a jade. (Owe 18:4.)

6. Ọpọlọpọ eniyan ni o maa npolongo iṣotitọ ara rẹ̀: ṣugbọn olootọ eniyan, tani yoo ri i. (Owe 25:14; Matt 6:2; Luk 18:11; Psm 12:1; Luk 18:8.)

7. Olootọ eniyan ti nrin ninu iwatitọ rẹ̀: ibukun ni fun awọn ọmọ rẹ̀ lẹhin rẹ̀! (2 Kor 1:12; Psm 37:26.)

8. Ọba ti o jokòó lori itẹ́ idajọ, o fi oju rẹ̀ fọ́n ìwà-ibi gbogbo ká. (ẹsẹ 26.)

9. Tani o le wi pe, "Mo ti mu àyà mi mọ́, emi ti mọ́ kuro ninu ẹ̀ṣẹ mi?" (1 A.Ọba 8:46; 1 Jhn 1:8.)

10. Iwọn oniruuru, ati òṣùwọ̀n oniruuru, gbogbo wọn bakan naa, ìrira loju Oluwa. (Deut 25:13; ẹsẹ 23.)

11. Ìṣe ọmọde paapaa ni a fi nmọ ọn, bí iwa rẹ ṣe rere ati títọ́. (Matt 7:16.)

12. Etí ti o ngbọ́ ati ojú ti o nri, Oluwa ni o da gbogbo wọn. (Eks 4:11.)

13. Máṣe fẹ́ oorun sísùn, ki o ma baa di táláká; ṣi ojú rẹ, a o si fi ounjẹ tẹ ọ lọrun. (Owe 6:9,10; Rom 12:11.)

14. "Ko ni laari, ko ni laari!" ni olùbárà nwí; ṣugbọn nigba ti o ba bọ́ si ọ̀nà rẹ̀, nigba naa ni oun yoo ṣogo.

**Ogún ti a kojọ wàràwàrà.**

15. Wura wà ati iyùn ọpọlọpọ: ṣugbọn ètè ìmọ̀, èlò iyebiye ni.

16. Gba aṣọ rẹ̀, nitori ti o ṣe onígbọ̀wọ́ fun àlejò, si gba ohun ẹ̀rí lọwọ rẹ̀ nigba ti o ba ṣe oniduro fun àjèjì obinrin. (Owe 27:13.)

17. Ounjẹ ẹ̀tàn dùn mọ eniyan; ṣugbọn nikẹhin, ẹnu rẹ̀ ni a o fi okuta wẹ́wẹ́ kún. (Owe 9:17.)

18. Pẹlu imọran ni a fi nfi ìdí ète gbogbo kalẹ̀; ati pẹ̀lú èrò rere ni ki o ṣígun. (Owe 15:22; 24:6; Luk 14:31.)

19. Ẹni ti o ba nkiri bi olofofo a maa fi ọ̀ràn ìkọ̀kọ̀ hàn: nitori naa ma ṣe bá ẹni ti nṣi ètè rẹ̀ laironu ṣiré. (Owe 11:13; Rom 16:18.)

20. Ẹnikẹni ti o ba bú baba rẹ̀ tabi ìyá rẹ̀, fitila rẹ̀ ni a o pa ninu okunkun biribiri. (Matt 15:4; Job 18:5.)

21. Ogún ti a yara jẹ latetekọṣe, ni a ki yoo bùkún ni òpin rẹ̀. (Owe 28:20.)

22. Iwọ maṣe wi pe, "Emi o gbẹsan ibi!", ṣugbọn duro de Oluwa, oun o si ran ọ lọwọ. (Rom 12:17; 1 Pet 3:9; Psm 27:14.)

23. Iwọn oníruurú ati òṣùwọ̀n ẹ̀tàn, ìrira ni loju Oluwa; ìwọ̀n irẹ́jẹ kò si dara.

24. Ìrìn tí eniyan nrin, aṣẹ Oluwa ni; tani nínú awọn eniyan ti o le mọ ọ̀nà rẹ̀? (Psm 37:23; Owe 16:9; Jer 10:23.)

25. Idękun ni fun eniyan lati yara şe ileri mímọ́, ki o to şẹ̀şẹ̀ ronú. (Onws 5:4,5.)

26. Ọlọgbọn ọba a tú eniyan buburu ká, a si mu ayika-kẹ̀kẹ́ rẹ̀ kọja lori wọn. (ẹsẹ 8.)

27. Ẹmí eniyan ni fitílà Oluwa, a maa şe àwárí ìkọ̀kọ̀ inu. (1 Kor 2:11.)

28. Aanu ati otitọ pa ọba mọ́: aanu ni a si fi ndi itẹ́ rẹ̀ mu. (Owe 29:14.)

29. Ogo awọn ọdọmọkunrin ni agbara wọn; ẹwà awọn arúgbó ni ewú. (Owe 16:31.)

30. Àpá ọgbẹ́ ni nwẹ ibi nù kuro: bẹẹ si ni ìnà-ẹgba nfọ ìkọ̀kọ̀ ikùn mọ́.

ORI 21.

**Işura ẹni-buburu.**

AYÀ ọba nbẹ lọwọ Oluwa bi odò omi; oun a si dari rẹ si ibikibi ti o wu u.

2. Gbogbo ọ̀nà eniyan ni o dara loju ara rẹ̀: şugbọn Oluwa ni o nwọn ọkàn. (Owe 16:2; 24:12; Luk 16:15.)

3. Lati şe ododo ati idajọ, o şe itẹwọgba fun Oluwa jù ẹbọ lọ. (1 Sam 15:22; Owe 15:8; Isa 1:11–17; Hos 6:6; Mika 6:7,8.)

4. Ìrera ojú, ati igberaga àyà, ati fitila eniyan buburu, ẹ̀şẹ̀ ni. (Owe 6:17.)

5. Ìrònú alaapọn yọrisi nini ọ̀pọ̀; şugbọn ti olukuluku ẹni ti o nkanju, yọrisi kìkì àìnító. (Owe 10:4; 28:22.)

6. Níní işura nipa ahọ́n èké, o jẹ ikuukuu ti a nfẹ́ kiri, ìdẹkùn ikú si ni pẹ̀lú. (2 Pet 2:3.)

7. Ìwà-agbara awọn eniyan buburu ni yoo pa wọn run: nitori ti wọn kọ̀ lati şe idajọ. (Owe 10:25.)

8. Ẹnikẹni ti o nrin ọ̀nà àyídáyidà, eniyan buburu ni; şugbọn oninu funfun ni işẹ́ rẹ tọ́

9. Ó sàn lati jokòó ni igun òkè àjà, ju pẹlu oníjà obinrin lọ ninu ile àjùmọ̀gbé. (Owe 25:24.)

10. Ọkàn eniyan buburu nwa ibi kiri: aladugbo rẹ̀ ko ri ojurere ni ojú rẹ̀. (Owe 2:14; 14:21.)

11. Nigba ti a bá jẹ ẹlẹ́gàn ni ìyà, a sọ òpè di ọlọgbọ́n: nigba ti a bá si nkọ́ ọlọgbọ́n, oun yoo si maa ni ìmọ̀. (Owe 19:25.)

12. Olododo nkẹ́dùn ilé eniyan buburu: şugbọn eniyan buburu a sì şubu sinu iparun. (Owe 14:11.)

**Işura ẹni ti ó gbọ́n.**

13. Ẹnikẹni ti o ba di etí rẹ̀ si igbe olupọnju, ountikararẹ yoo ké pẹlu: sugbọn a ki yoo gbọ́. (Matt 18:30–34; 1 Jhn 3:17; Jak 2:13.)

14. Ọrẹ ìkọ̀kọ̀, mu ibinu kuro: ati owó-àbẹ̀tẹ́lẹ̀ lati ibi ìkọ̀kọ̀ wá, dẹ́kun ibinu lile. (Owe 18:16; 19:6.)

15. Ayọ̀ ni fun olododo lati şe idajọ: şugbọn iparun ni fun awọn onişẹ ẹ̀şẹ̀.

16. Ẹni ti o ba yà kuro ni ọ̀nà oye, yoo maa gbe inu ijọ awọn òkú. (Psm 49:14.)

17. Ẹni ti o ba fẹ afẹ́, yoo di talaka: ẹni ti o fẹ ọtí-waini pẹlu orórò ko le lọ́rọ̀.

18. Eniyan buburu ni yoo şe owó-irapada fun olododo, ati olurekọja fun ẹni diduro-şinşin. (Owe 11:8.)

19. Ó sàn lati jokòó ni aginju ju pẹlu onija obinrin ati oşónú lọ. (ẹsẹ 9).

20. Işura iyebiye ati orórò wa ni ibùgbé ọlọgbọn; şugbọn eniyan aşiwère (omugọ) jẹ ẹ run. (Owe 22:4; Job 20:15,18.)

21. Ẹni ti o ba tẹle ododo ati aanu, yoo ri ìyè, ododo, ati ọlá. (Matt 5:6.)

22. Ọlọgbọn goke odi ilu awọn alagbara, o si bi ibi-giga agbara igbẹkẹle wọn şubu. (Onws 9:15,16.)

23. Ẹnikẹni ti o ba pa ẹnu ati ahọn rẹ̀ mọ, o pa ọkan rẹ̀ mọ kuro ninu ìyọnu. (Owe 12:13; Jak 3:2.)

24. "Alagidi" ni orukọ agberaga ati ẹlẹgan, ti nhuwa ninu àdábọwọ́ igberaga. (Psm 1:1; Owe 1:22; Isa 16:6; Jer 48:29.)

25. Ìfẹ́ ọ̀lẹ pa á; nitori ti ọwọ́ rẹ̀ kọ işẹ́ şişe. (Owe 13:4; 20:4.)

26. O nfi ilara şojúkòkòrò ni gbo-

gbo ọjọ: ṣugbọn olododo a maa fi funni kií si i dawọduro. (Psm 37:26; Matt 5:42; Ef 4:28.)

27. Ẹbọ eniyan buburu, irira ni: melomelo ni nigba ti o mu un wá pẹlu èrò iwa-ibi? (Isa 66:3; Jer 6:20; Amos 5:22.)

28. Ẹlẹri èké yoo ṣegbe: ṣugbọn ọ̀rọ̀ ẹni ti o gbọ́, yoo duro. (Owe 19:5,9.)

29. Eniyan buburu mu ojú ara rẹ̀ le: ṣugbọn ẹni iduro-ṣinṣin ni o nmu ọ̀nà rẹ̀ tọ́. (Onws 8:1.)

30. Ko si ọgbọ́n, ko si ìmọ̀ye, tabi imọran ti o le moke niwaju Oluwa. (Isa 8:9,10; Jer 9:23; A.A. 5:39.)

31. A nmura ẹṣin silẹ de ọjọ ogun: ṣugbọn iṣẹgun jẹ́ ti Oluwa. (Isa 31:1; Psm 3:8; 1 Kor 15:28.)

## ORÍ 22

**Orukọ rere sàn ju ọrọ̀ lọ.**

ORÚKỌ rere sàn ni yiyan ju ọrọ̀ pupọ lọ, ati ojurere dara ju fadaka ati wura lọ. (Onws 7:1.)

2. Ọlọ́rọ̀ ati talaka pejọ pọ̀: Oluwa ni ẹlẹda gbogbo wọn.

3. Ọlọgbọn eniyan ti rí ibi tẹlẹ, o si pa ara rẹ̀ mọ: ṣugbọn awọn òpè tẹ̀ siwaju, a si jẹ wọn níyà. (Owe 14:16; 27:12.)

4. Èrè irẹlẹ ati ibẹru Oluwa ni ọrọ̀, ọlá, ati iyè.

5. Ẹgún ati idẹkun nbẹ ni ọ̀nà alayidayida: ẹni ti o ba pa ọkan rẹ̀ mọ́ yoo jinna si wọn. (Owe 15:19.)

6. Tọ́ ọmọde ní ọ̀nà ti yoo tọ̀: nigba ti o ba dagba, ki yoo kuro ninu rẹ̀. (Ef 6:4.)

7. Ọlọ́rọ̀ ṣe olori olupọnju, ajigbèsè si ṣe iranṣẹ fun ẹni ti a jẹ nígbèsè. (Owe 18:23; Jak 2:6.)

8. Ẹni ti o ba funrugbin ẹ̀ṣẹ̀, yoo ka asán: ọ̀pá ibinu rẹ̀ yoo kùnà. (Owe 24:16; Psm 125:3.)

9. Ẹni ti o ni ojú aanu ni a o bukun fun; nitori ti o fi ninu ounjẹ rẹ fun olupọnju. (2 Kor 9:6.)

10. Le ẹlẹgan si ìta, ìjà yoo si jade; nitootọ ìjà ati ẹ̀gàn yoo dẹkun. (Owe 18:6; 26:20.)

11. Ẹni ti o fẹ ìwà-funfun ti àyà, ti o si nsọrọ iyì jade, ọba yoo ṣe ọrẹ́ rẹ̀. (Matt 5:8; Owe 16:13.)

12. Oju Oluwa pa imọ mọ́, ó si yí ọ̀rọ̀ olurekọja po. (Owe 21:12.)

13. Ọlẹ wi pe, "Kinniun nbẹ lode, a o pa mi ni igboro!" (Owe 26:13.)

14. Ẹnu awọn àjèjì obinrin, ihò jinjin ni; ẹni ti a nbinu sí lati ọdọ Oluwa wa ni yoo ṣubu sinu rẹ̀. (Owe 2:16; 5:3; 23:27; Onws 7:26.)

15. Àyà ọmọde ni iwa-wèrè dì si; ṣugbọn paṣan itọni ni yoo le e jinna kuro lọdọ rẹ̀. (Owe 13:24; 23:14.)

16. Ẹni ti o nni talaka lara lati mu ọrọ̀ pọ̀, ti o si nta ọlọ́rọ̀ lọrẹ, yoo di alaini bi o ti wu ki ó rí.

**Gbọ ọ̀rọ̀ ọlọgbọn eniyan.**

17. Dẹtí rẹ silẹ, ki o gbọ ọ̀rọ̀ awọn ọlọgbọn, ki o si fi àyà rẹ si ẹ̀kọ́ mi. (Owe 5:1; 23:12.)

18. Nitori ohun didun ni bi iwọ ba pa wọn mọ́ ni inu rẹ; nigba ti a si pèsè wọn tan ni ètè rẹ. (Owe 2:10.)

19. Ki igbẹkẹlẹ rẹ lè wa niti Oluwa, emi fi han ọ loni, ani fun ọ. (Owe 3:5.)

20. Emi kò ha ti kọwe ohun daradara si ọ niti ìmọ̀ràn ati niti ẹ̀kọ́, (Owe 8:6,10.)

21. Ki o le mu ọ mọ didaju ọ̀rọ̀ òtítọ́; ki iwọ le maa fi idahun otitọ fun awọn ti o rán ọ? (Luk 1:3,4.)

22. Maṣe ja talaka ni olè, nitori ti o jẹ talaka: bẹẹ ni ki o ma si ṣe ni olupọnju lara ni ibode: (Sek 7:10; Mal 3:5.)

23. Nitori Oluwa yoo gbeja wọn, yoo si gba ọkàn awọn ti ngba tiwọn naa. (1 Sam 25:39; Psm 12:5; 35:10; Owe 23:11.)

24. Maṣe ba onibinu eniyan ṣe ọrẹ́; ma si ṣe ba ọkunrin oninu-fufu rin.

25. Ki iwọ ma baà kọ́ iwa rẹ̀, iwọ a si gba ìkẹ́kùn fun ara rẹ.

26. Maṣe wa ninu awọn ti nṣe ìgbòwọ́, tabi ninu awọn ti o duro fun igbèsè. (Owe 11:15.)

27. Bi iwọ ko ba ni nkan ti iwọ o fi san, nitori kinni yoo ṣe gba ẹní rẹ kúrò lábẹ́ rẹ̀?

28. Maṣe yẹ aala-ilẹ igbani, ti awọn baba rẹ ti pa. (Owe 23:10.)

29. Iwọ ha ri eniyan ti o nfi aiṣimẹ́lẹ́ ṣe iṣẹ rẹ̀? Oun yoo duro niwaju awọn ọba; oun ki yoo duro niwaju awọn eniyan lásán. (Rom 12:11; 1 A.Ọba 10:8.)

ORI 23.

**Ifẹkufẹ ohun àdídùn.**

NIGBA ti iwọ ba jokòó lati ba ìjòyè jẹun, kiyesi oun ti o wa niwaju rẹ gidigidi.

2. Iwọ a si fi ọ̀bẹ lé ara rẹ ni ọ̀fun, bi iwọ ba jẹ́ òkúndùn eniyan. (ẹsẹ 20.)

3. Máṣe fẹ ounjẹ-didùn rẹ̀: nitori pé ounjẹ ẹ̀tàn ni. (ẹsẹ 6; Psm 141:4.)

4. Máṣe ṣe làálàá lati lọ́rọ̀: ṣiwọ kuro ninu ọgbọ́n ara rẹ. (Owe 28:20; 1 Tim 6:9,10; Rom 12:16.)

5. Iwọ o ha fi oju rẹ lepa ohun ti kò si? Nitori ti ọ̀rọ̀ hu iyẹ-apa fun ara rẹ̀, o si nfò bí ìdì ni oju ọrun. (Owe 27:24.)

6. Máṣe jẹ ounjẹ oloju buburu, bẹẹ ni ki o ma si ṣe fẹ ounjẹ-didun rẹ̀. (Psm 141:4.)

7. Nitori pe bi ẹni ti nṣiro ni ọkàn rẹ̀, bẹẹ ni o ri: "Maa jẹ, ki o si maa mu!" ni o nwi fun ọ; ṣugbọn ọkàn rẹ̀ ko pẹlu rẹ. (Owe 26:24,25.)

8. Òkèlè ti iwọ jẹ ni iwọ o pọ jade, iwọ a si sọ ọ̀rọ̀ didun re nu.

9. Màṣe sọ̀rọ̀ ni eti aṣiwère (omugọ); nitori ti yoo gan ọgbọn ọ̀rọ̀ rẹ. (Matt 7:6; Owe 1:7.)

10. Màṣe ṣi àlà àtijọ́ kúrò; ma si ṣe bọ sinu oko alaini-baba. (Owe 22:28; Jer 22:3; Sek 7:10.)

11. Nitori pé Olurapada wọn lagbara; yoo gba ìjà wọn jà si ọ. (Owe 22:23.)

12. Fi àyà si ẹ̀kọ́, ati etí rẹ si ọ̀rọ̀ ìmọ̀. (Owe 22:17.)

13. Maṣe fa ọwọ ibawi sẹ́hìn kúrò lara ọmọde, nitori pe bi iwọ ba fi pàṣán na a, oun ki yoo ku. (Owe 13:24; 19:18; 22:15.)

14. Bi iwọ fi paṣan na a, iwọ o si gbà ọkàn rẹ la kuro ni ọrun-apadi.

**Ọ̀rọ̀ ọgbọ́n fun ọmọ rere.**

15. Ọmọ mi, bi ọkan rẹ ba gbọ́n, ọkan mi yoo yọ̀, àní emi pẹlu.

16. Inu mi yoo si dun nigba ti ètè rẹ ba nsọrọ titọ́. (ẹsẹ 24,25; Owe 27:11.)

17. Maṣe jẹ ki àyà rẹ o ṣe ilara si awọn ẹlẹ́ṣẹ̀, ṣugbọn ki iwọ o wà ni ibẹru Oluwa, ni ọjọ gbogbo. (Psm 37:1; Owe 28:14.)

18. Nitori pe ikẹhin nbẹ nitootọ; ireti rẹ ki yoo si ge kuro.

19. Gbọ, iwọ ọmọ mi, ki o si gbọn, ki o si maa tọ́ àyà rẹ̀ si ọna titọ.

20. Máṣe wà ninu awọn ọmuti; ati awọn wọ̀bìà alájẹkì ọ̀jẹun; (Isa 5:22; Matt 24:49; Luk 21:34; Rom 13:13; Ef 5:18.)

21. Nitori pé ọmuti ati ọjẹun ni yoo di talaka; imuni-toogbe ni si nfi àkísà wo ọkunrin láṣọ. (Owe 21:17; 6:10, 11.)

22. Feti si ti baba rẹ ti o bi ọ, ma si ṣe gan iyá rẹ, nigba ti o ba gbó. (Owe 1:8; 30:17; Ef 6:1.)

23. Ra otitọ, ki o ma si ṣe ta a; ra ọgbọn pẹlu ati ẹkọ, ati oye. (Owe 4:5,7; Matt 13:44.)

24. Baba olododo ni yoo yọ gidigidi: ẹni ti o si bi ọmọ ọlọgbọn, yoo ni ayọ ninu rẹ̀. (Owe 10:1; 15:20.)

25. Jẹ ki baba rẹ ati iya rẹ o yọ, si jẹ ki inu ẹni ti o bi ọ dun.

26. Ọmọ mi, fi àyà rẹ fun mi, ki o si jẹ ki oju rẹ ni inu-didun si ọ̀nà mi. (Owe 3:1; 4:4; Psm 1:2.)

27. Nitori pe panṣaga-obinrin, ọ̀gbun jinjin ni; ati ajeji-obinrin, kanga hiha ni. (Owe 22:14.)

28. Oun a si luba bi olè, a si sọ awọn olurekọja di pupọ ninu awọn eniyan. (Owe 7:12; Onws 7:26.)

29. Tani o ni ọ̀ṣì? Tani o ni ibanujẹ? Tani ó ni ìjà? Tani o ni asọ̀? Tani o ni ọgbẹ́ lainidi? Tani o ni ojú pípọ́n? (Isa 5:11,22.)

30. Awọn ti o duro pẹ́ nibi ọti-waini; awọn ti nlọ lati dan ọti-waini àdalu wò. (Ef 5:18; Psm 75:8.)

31. Iwọ máṣe wò ọti-waini nigbà ti o pọn, nigba ti o ba nfi àwọ̀ rẹ̀ hàn ninu ago, ti a ngbe e mi, ti o ndùn.

32. Nikẹhin oun a buniṣán bi ejò, a si bunijẹ bi paramọ́lẹ̀.

33. Oju rẹ yoo wò awọn àjèjì obinrin, àyà rẹ yoo si sọ̀rọ̀ àyidáyidà. (Owe 2:12.)

34. Nitootọ, iwọ o dabi ẹni ti o dubulẹ ni aarin òkun, tabi ẹni ti o dubulẹ loke òpó-ọkọ̀.

35. Iwọ o si wi pe, " Wọn lù mi; ko dùn mi; wọn lù mi, emi kò si mọ̀: nigbawo ni emi o ji? Emi o tun maa wa omiran lati mu." (Jer 5:3.)

## ORI 24.

IWỌ máṣe ṣe ilara si awọn eniyan buburu, bẹẹ ni ki o ma si ṣe fẹ́ lati ba wọn gbé. (Psm 37:1; 73:3; Owe 3:31.)

2. Nitori ti àyà wọn ngbiro iparun, ètè wọn si nsọrọ iwa-ìkà. (Jer 22:17; Job 15:35.)

**Wiwọn ọgbọ́n wò.**

3. Ọgbọn ni a fi nkọ́ ile; òye ni a si fi nfi ìdí rẹ kalẹ̀. (Owe 9:1.)

4. Nipa ìmọ̀ ni iyara fi nkun fun oniruuru ọrọ̀ iyebiye ti o jọjú.

5. Ọlọgbọn eniyan ni agbara ju alagbara lọ, nitootọ eniyan ìmọ̀ a sọ agbara rẹ̀ di pupọ̀. (Owe 21:22.)

6. Nitori nipa ìtọni ọgbọn ni iwọ o fi ja ogun rẹ; ati ninu ọ̀pọ̀ awọn olúgbìmọ̀ ni ìṣẹgun wà.(Luk 14:31.)

7. Ọgbọ́n ga jù pupọ fun omugọ lọ: oun ki yoo ya ẹnu rẹ̀ ni ẹnu-bode. (Psm 10:5.)

8. Ẹni ti nhùmọ̀ lati ṣe ibi ni a o pè ni eniyan ìwà-ìkà. (Owe 6:14; Rom 1:30.)

9. Gbígbèrò iwa-wèrè, ẹ̀ṣẹ̀ ni; irira ninu eniyan si ni ẹlẹ́gàn.

10. Bi iwọ ba rẹ̀wẹ̀sì ni ọjọ́ ipọnju, agbara rẹ kò tó nkan. (Jer 51:46; Heb 12:3.)

11. Gba awọn ti a wọ́ lọ sinu ikú là, ati awọn ti a yàn fun pipa. (Psm 82:4; Isa 58:6,7.)

12. Bi iwọ ba si wi pe, "Kíyèsii awa kọ mọ èyí": njẹ ẹni ti nwọn ọkàn wò ko ha ri i bi? Ẹni ti npa ọkàn rẹ mọ́, ko ha mọ̀ bi, ki yoo ha san an fun eniyan gẹgẹ bi iṣẹ rẹ bi? (Owe 21:2; Onws 5:8; Psm 121:3–8; 94:9,11; Owe 12:14.)

**Ìmọ̀ràn fun ọmọ rere.**

13. Ọmọ mi, jẹ oyin, nitori ti o dara; ati afárá oyin, ti o dun ni ẹnu rẹ: (O.Sol. 5:1.)

14. Bẹẹ ni ìmọ̀ ọgbọn yoo ri si ọkàn rẹ: bi iwọ ba ri i, nigba naa ni èrè yoo wa, a ki yoo si mu ireti rẹ kuro. (Owe 2:10.)

15. Máṣe ba ni ibùba bi eniyan buburu, lati gba ibujokòó olododo: máṣe fi ibi isinmi rẹ̀ ṣe ìjẹ. (Psm 10:9,10.)

16. Nitori pe olootọ a ṣubu nigba meje, a si tun dide: ṣugbọn eniyan buburu yoo ṣubu sinu ibi. (Psm 34:19; Mika 7:8; ẹsẹ 22.)

17. Máṣe yọ̀ nigba ti ọ̀tá rẹ ba ṣubu, ma si ṣe jẹ ki inu rẹ o dun nigba ti o ba kọsẹ̀: (Job 31:29; Obad 12.)

18. Ki Oluwa má ba ri i, a si buru ni oju rẹ̀, oun a si yi ibinu rẹ̀ pada kuro lori rẹ̀.

19. Máṣe ṣe ilara si awọn eniyan buburu, ma si ṣe jowú eniyan buburu. (Psm 37:1.)

20. Nitori pe, èrè ki yoo si fun eniyan ibi; fitila eniyan buburu ni a o pa. (Owe 13:9.)

21. Ọmọ mi, bẹru Oluwa ati ọba: ki iwọ má si ṣe dàpọ̀ mọ awọn ti nṣe àyídáyidà. (Rom 13:1–7; 1 Pet 2:17.)

22. Nitori pé wahala lati ọ̀dọ̀ wọn wá yoo dide lojijì, ati iparun ti yoo de lati ọwọ́ awọn mejeji, tani o mọ ọn!

**Ọ̀rọ̀ ọlọgbọn.**

23. Wọnyìí pẹlu ni ọ̀rọ̀ awọn ọlọgbọn; Ko dara lati ṣe ojuṣaju ni idajọ. (Owe 1:6; 18:5; Lef 19:15; Deut 1:17.)

24. Ẹni ti ọ ba wi fun ẹniyan buburu pe, "Olododo ni iwọ", oun ni awọn eniyan yoo bú, awọn orilẹ-èdè yoo si korira rè. (Owe 17:15.)

25. Ṣugbọn awọn ti o bá a wi ni yoo ni inu-didun, ibukun rere yoo si bọ sori wọn. (Owe 28:23.)

26. Ẹni ti o ba ṣe idahun rere dabi ẹni ti o ṣe ìfẹnukonu.

27. Mura iṣẹ rẹ silẹ lode, ki o si fi ìtara tulẹ̀ ni oko rẹ; nikẹhin eyi, ki o si kọ ile rẹ.

28. Máṣe ṣe ẹlẹri si ẹnikeji rẹ lainidi: ki o ma si ṣe fi ètè rẹ ṣẹ̀tàn. (Owe 25:18; Ef 4:25.)

29. Máṣe wi pe, "Bẹẹ ni emi o ṣe si i, gẹgẹ bi o ti ṣe si mi: emi o san an fun ọkunrin naa gẹgẹ bi iṣẹ rẹ̀." (Owe 20:22; Matt 5:39; Rom 12:17.)

30. Mo kọja lọ ni oko ọ̀lẹ, ati lẹba ọgbà-àjàrà ẹni ti òye kù fun; (Owe 6:6–11.)

31. Si kiyesii, ẹ̀gún kun bo gbogbo rẹ̀, ẹ̀gún ọ̀yàn si bo ojú rẹ̀, ìgànná okuta rẹ̀ si wo lulẹ̀. (Owe 13:23.)

32. Nigba naa ni mo ri, mo si fi ọkàn mi si i gidigidi: mo wo o, mo si gba ẹ̀kọ́.

33. Orun diẹ, òògbé díẹ̀, ikawọjọpọ̀ lati sun diẹ. (Owe 6:9; 20:13.)

34. Bẹẹ ni òṣì rẹ̀ yoo de bi ọlọ́ṣà; ati aini rẹ̀ bi ọkunrin ti o hamọra ogun.

## ORI 25.

**Ìmọ̀ràn nipa ìwà ati ìṣe niwaju Ọba.**

WỌNYÌÍ pẹlu ni òwe Solomoni, ti awọn ọkunrin Hesekiah, ọba Judah kọ silẹ. (Owe 1:1.)

2. Ogo Ọlọrun ni lati pa ọ̀ràn mọ́: ṣugbọn ọlá awọn ọba ni lati wadi ọ̀ràn. (Deut 29:29; Esra 6:1.)

3. Ọrun fun giga, ati ilẹ̀ fun jínjìn, bẹẹ ni inu awọn ọba kò ṣe wadi.

4. Mu ìdàrọ́ kuro ninu fàdákà, ohun-elo yoo si jade fun alagbẹdẹ fàdákà. (2 Tim 2:21.)

5. Mu eniyan buburu kuro niwaju ọba, a o si fi ìdí ìtẹ́ rẹ̀ kalẹ̀ ninu ododo. (Owe 20:8; 16:12.)

6. Máṣe ṣeféfé niwaju ọba, ma si ṣe duro ni ipò awọn eniyan nlá.

7. Nitori pé, o san ki a wi fun ọ pé, "Wa soke nihin", ju ki a rẹ ọ silẹ̀ niwaju ọmọ-alade ti oju rẹ ti rí ọ. (Luk 14:7–11.)

8. Máṣe jade lọ kánkán lati jà, ki iwọ ma baa ṣe alaimọ eyi ti iwọ o ṣe ni opin rẹ̀, nigba ti aladugbo rẹ bá dojuti ọ. (Matt 5:25.)

9. Ba ẹnikeji rẹ ṣè àlàyé ọ̀rọ̀; ṣugbọn aṣiri ẹlomiran ni iwọ kò gbọdọ fihàn. (Matt 18:15; Owe 11:13.)

10. Ki ẹni ti o ba gbọ́ má baa dojuti ọ, ẹ̀gàn rẹ ki yoo si lọ kuro lae.

11. Bi èso igi wura ninu agbọ̀n fadaka, bẹẹ ni ọ̀rọ̀ ti a sọ ni àkókò rẹ̀. (Owe 15:23.)

12. Bi òrùka wura ati ohun ọ̀ṣọ́ wura daradara, bẹẹ ni ọlọgbọn olubaniwi rí si etí ti ngbọran. (Owe 15:31; 20:12.)

13. Bi òtútù ojo-dídì ni ìgbà ikore, bẹẹ ni olootọ ikọ̀ rí si awọn ti o ran an: nitori ti o tu awọn ọ̀gá rẹ̀ ninu. (Owe 13:17.)

14. Ẹnikẹni ti o ba ṣeféfé ninu ẹ̀bùn ẹ̀tàn, o dabi ikuukuu awọsanma ati afẹ́fẹ́ ti ko ni òjò. (Owe 20:6; Ondj 12.)

**Aladugbo ati ọ̀tá rẹ.**

15. Ipamọra pípẹ́ ni a fi nyi ọmọ-alade ni ọkàn pada, ahọn ti o kunna ni nfọ egungun. (Gen 32:4; 1 Sam 25:24; Owe 15:1; 16:14.)

16. Bi iwọ ba ri oyin, jẹ èyí ti o tọ fun ọ, ki o ma ba sú ọ, iwọ a si bi i. (ẹse 27.)

17. Fa ẹsẹ sẹhin kúrò ni ilé aladugbo rẹ; ki agara rẹ má baa da a, oun a si korira rẹ.

18. Ẹni ti o jẹri èké si ẹnikeji rẹ̀, dabi òlùgbóró, ati idà, ati ọfa mímú. (Psm 57:4; Owe 12:18.)

19. Igbẹkẹle alaiṣootọ eniyan ni ìgbà ipọnju, o dabi ehín tí o ṣẹ, tabi ẹsẹ̀ ti o yẹ lori ìké.

20. Bi ẹni ti o bọ aṣọ nigba òtútù, ati

bi ọti-kikan ninu eeru, bẹẹni ẹni ti nkọrin fun ẹni ti inu rẹ bajẹ.

21. Bi ebi ba npa ọta rẹ, fun un ni ounjẹ; bi oungbẹ ba si ngbẹ ẹ, fun un ni ohun mimu. (Eks 23:4,5; Matt 5:44; Rom 12:20.)

22. Nitori ti iwọ o ko ẹyin iná jọ si orí rẹ, Oluwa yoo san fun ọ. (2 Sam 16:12; Rom 12:20.)

23. Afẹfẹ ariwa mu òjò wa, bẹẹ ni ahọn ti nsọrọ-ẹni-lẹhin nmu ojú kikoro wa. (Psm 101:5.)

24. O sàn lati jokòó ni igun oke àjà, ju pẹlu oníjà obinrin lọ ninu ile àjùmọ̀gbé. (Owe 21:9.)

25. Bi omi tutu ṣe ri si ọkan ti oungbẹ ngbẹ, bẹẹ ni ihin-rere lati ilu okere wa. (ẹsẹ 13; Owe 15:30.)

26. Olododo ti o ṣipo pada niwaju eniyan buburu, o dabi orisun-omi ti o ru, ati isun-omi ti o díbàjẹ́. (Esk 32:2; 34:18,19.)

27. Ko dara lati jẹ oyin púpọ̀; bẹẹ ni kii ṣe ògo fun awọn eniyan ti nwá ogo fun ara wọn. (ẹsẹ 16; Owe 27:2.)

28. Ẹni ti kò lè ṣe akoso ẹ̀mi rẹ̀, o dabi ilu ti a wó lulẹ̀, ti ko si ni odi. (Owe 16:32.)

## ORI 26.

**Òmùgọ̀ ati iwà-omugọ rẹ̀.**

BI òjò-didi ní igba ẹ̀rùn, ati bi òjò ni ìgbà ikore, bẹẹ ni ọlá ko yẹ fun aṣiwère (omugọ). (1 Sam 12:17.)

2. Bi ẹyẹ ológoṣẹ́ ti nṣíkiri, ati bi alápàndẹ̀dẹ̀ ti nfò, bẹẹ ni ègún ki yoo wá lainidi. (Num 23:8; Deut 23:5.)

3. Ẹgba fun ẹṣin, ìjanu fun kẹtẹkẹtẹ, ati ọ̀gọ fun ẹhin aṣiwère (omugọ). (Psm 32:9.)

4. Máṣe da asiwère (omugọ) lohùn gẹgẹ bi iwa-omugọ rẹ̀, ki iwọ paapaa maa bá dabi rẹ̀. (Owe 23:9; 29:9.)

5. Da aṣiwère (omugọ) lohun gẹgẹ bi iwa-omugọ rẹ̀, ki o má ba gbọn ni oju ara rẹ̀. (Matt 16:1–4; 21:24–27.)

6. Ẹni ti o ti ọwọ aṣiwèrè (òmùgọ̀), rán iṣẹ́ o ge ẹsẹ ara rẹ̀ kuro, o si mu ibàjẹ́.

7. Bi ẹsẹ̀ mejeji ti rọ̀ silẹ lara amọ́kùn, bẹẹ ni òwe ni ẹnu awọn aṣiwère (omugọ). (ẹsẹ 9.)

8. Bi ẹni ti o fi okuta sinu kannakanna, bẹẹ ni ẹni ti nfi ọlá fun aṣiwère (òmùgọ̀). (ẹsẹ 1.)

9. Bi ẹgun ti ngún ọmuti lọwọ, bẹẹ ni òwe ni ẹnu awọn aṣiwère (omugọ). (ẹsẹ 7.)

10. Bi tafatafa ti o mu gbogbo eniyan gbọgbẹ́, bẹẹ ni ẹni ti o gbà aṣiwère (omugọ) si iṣẹ, ti o si gba awọn olurekọja si iṣẹ-owó.

11. Bi ajá ti npada sinu eebi rẹ̀, bẹẹ ni aṣiwère – (omugọ) tun npada sinu iwa-òmùgọ̀ rẹ̀. (2 Pet 2:22; Eks 8:15.)

12. Iwọ ri ẹnikan tí o gbọ́n ni ojú ara rẹ̀? ireti nbẹ fun aṣiwère (omugọ) ju fun un lọ. (ẹsẹ 5; Owe 3:7; 29:20.)

**Ọlẹ eniyan ati ètè ẹ̀tàn.**

13. Ọlẹ eniyan wi pe, "Kinniun nbẹ ni ọ̀nà; kinniun nbẹ ni igboro."

14. Bi ilẹkun ti nyi lori àgbékà rẹ̀, bẹẹ ni ọlẹ lori ẹní rẹ̀.

15. Ọlẹ pa ọwọ rẹ̀ mọ́ sinu iṣásun; kò si le yọ ọ jade pada wa si ẹnu rẹ̀. (Owe 19:24.)

16. Ọlẹ gbọ́n ni oju ara rẹ̀ ju eniyan meje lọ ti wọn le fi ọgbọ́n dahun ọ̀ràn.

17. Ẹni ti nkọja lọ, ti o si dasi ìjà ti ki iṣe tirẹ̀, o dabi ẹni ti o mu ajá létí. (Owe 3:30.)

18. Bi asíwín ti nsọ ọ̀kọ̀, ọfà ati ikú. (Isa 50:11.)

19. Bẹẹ ni ẹni ti o tan ẹnikeji rẹ̀ jẹ, ti o si wi pe, "Eré ni emi nṣe!" (Owe 24:28.)

20. Nigba ti igi bá tán, ina á kú bẹẹ ni nigba ti olófofó kò sí, ìjà a dá. (Owe 16:28; 22:10.)

21. Bi èédú ti ri si ẹ̀yin-iná, ati igi si iná; bẹẹ ni eniyan onija lati da ìjà sílẹ̀. (Owe 15:18.)

22. Ọ̀rọ̀ olófofó dabi àdíndùn, wọn a si wọ ìsàlẹ̀ inu lọ. (Owe 18:8.)

23. Ètè jíjóòwò, ati àyà buburu, dabi ìdàrọ́ fadaka ti a fi bo ìkòkò.

24. Ẹni ti o ba korira, ti o fi ètè rẹ̀ ṣe

àgàbàgebè, yoo si pa ętàn mọ ninu rẹ̀. (Owe 10:18; 12:20.)
25. Nigba ti o ba sọrọ daradara, maṣe gba a gbọ: nitori pe irira meje ni o wa ni àyà rẹ̀. (Psm 28:3; Jer 9:8.)
26. Ẹnikẹni ti a fi ẹ̀tàn bo irira rẹ mọ́lẹ̀, iwa-buburu rẹ̀ ni a o fi han niwaju gbogbo ijọ. (Matt 23:28.)
27. Ẹnikẹni ti o ba wa ihò yoo ṣubu sinu rẹ̀: ẹni ti o ba si nyi okuta, oun ni yoo pada tọ̀. (Psm 7:15; Owe 28:10; Onws 10:8.)
28. Ahọn èké korira awọn ti a fi njẹniya; ẹnu ipọnni a si ma ṣiṣẹ́ iparun. (Owe 29:5.)

## ORI 27.

**Ọgbọn fun ònì ati fun ọ̀lá.**

MÁṢE lérí ara rẹ niti ọjọ ọ̀la, nitọri ti iwọ kò mọ̀ ohun ti ọjọ́ kan yoo hù jade. (Luk 12:19,20; Jms 4:14.)
2. Jẹ ki ẹlomiran yin ọ, ki ó máṣe ẹnu ara rẹ; alejo, ki o ma si ṣe jẹ ete ara rẹ. (Owe 25:27; 2 Kor 10:12,18.)
3. Okuta wuwo, iyanrin si lóòrin, ṣugbọn ibinu aṣiwère, (omugọ) o wuwo ju mejeeji lọ. (Owe 12:16.)
4. Ibinu ni ìkà, irunu si buru rẹ̀kọjá; ṣugbọn tani yoo duro niwaju owú?
5. O dara lati fi ìbáwí hàn ju ìfẹ́ ti o farasin lọ. (Owe 28:23.)
6. Otitọ ni ọgbẹ́ òrẹ́: sugbọn ifẹnukonu ọta ni ẹ̀tàn.
7. Ọkàn ti ó yó fi ẹsẹ̀ tẹ afara-oyin; ṣugbọn ọkàn ti ebi npa, ohun kíkorò gbogbo ni o dùn. (Owe 25:16.)
8. Bi ẹyẹ ti nfo kakiri lati inú ìtẹ́ rẹ̀, bẹẹ ni eniyan ti o nrin kiri jinna si ipò rẹ̀.
9. Oróró ati tùràrí mu ọkàn dùn; bẹẹ ni adùn ọrẹ ẹni nipa imọran atọkanwa.
10. Ọ̀rẹ́ rẹ, ati ọrẹ baba rẹ, máṣe kọ silẹ; bẹẹ ni ki o máṣe lọ si ilé arakunrin ni ọjọ idaamu rẹ: nitori pé aládugbo ti o sunmọ ni, o sàn ju arakunrin ti o jinna rere lọ. (2 Kro 10:6–8; Owe 17:17; 18:24.)
11. Ọmọ mi, ki iwọ o gbọn, ki o si mu inu mi dùn; ki emi le da ẹni ti ngan mi lohun. (Owe 10:1; 23:15; Psm 119:42.)
12. Amoye eniyan ri ibi tẹ́lẹ̀, o si pa ara rẹ̀ mọ́; ṣugbọn awọn òpè kọja, a si jẹ wọn níyà. (Owe 22:3.)
13. Gba aṣọ rẹ̀ nitori ti o ṣe onigbọwọ alejo, si gba ohun èrí lọ́wọ́ rẹ̀ fun ajeji obinrin. (Owe 20:16.)
14. Ẹni ti o nfi ohùn rara yẹ́ ọrẹ rẹ̀ si ni kutukutu owurọ, egún ni a o ka a si fun un.
15. Ọṣọ̀rọ̀-òjò ni ìgbà ojo, ati onija obinrin, bakannaa ni. (Owe 19:13.)
16. Lati dáa-lẹ́kun dabi didá afẹfẹ lẹ́kun, tabi bi igba ti a fi ọwọ ọtun ẹni gbá ororo mu.

**Eniyan ko le ni itẹlọrun.**

17. Irin a maa pọn irin: bẹẹ ni ọkunrin npọn oju ọrẹ rẹ̀.
18. Ẹnikẹni ti o tọju igi-ọ̀pọ̀tọ́ yoo jẹ eso rẹ̀; bẹẹ ni ẹni ti o duro ti ọ̀gá rẹ̀ ni a o buyin fun. (1 Kor 9:7; Luk 12:42–44; 19:17.)
19. Bi ninu omi, oju ndahun si oju, bẹẹ ni àyà eniyan nfi eniyan han.
20. Isà-òkú ati ibi iparun ki i kún; bẹẹ ni, oju eniyan ki, nitẹlọ́rùn. (Hab 2:5; Onws 1:8.)
21. Bi koro fun fadaka, ati ileru fun wura; bẹẹ ni eniyan si iyìn rẹ̀. (Luk 6:26.)
22. Bi iwọ tilẹ̀ fi ọmọlẹ-odo gun aṣiwere (Omugọ) ninu odo laarin alikama, iwa-omugọ ki yoo fi i silẹ. (Owe 23:35; Jer 5:3.)
23. Jẹ olóye eniyan lati mọ ìwà agbo-ẹran rẹ̀, ki o si bojuto awọn ọ̀wọ́-ẹran rẹ.
24. Nitori pe ọrọ̀ ki i wa titi lae: adé ha le maa wa de irandiran bi? (Owe 23:5; Job 19:9.)
25. Koriko yọ, ati ọ̀mùnú koriko fi ara han, ati ewebẹ awọn oke kojọ pọ̀. (Psm 104:14.)
26. Awọn ọ̀dọ́ agutan yoo pèsè fun aṣọ rẹ̀, awọn òbúkọ si ni iye-owo oko.

27. Iwọ o si ni wara ewurẹ tó fun ounjẹ rẹ, fun awọn ara ile rẹ ati fun ounjẹ awọn iranṣẹ-binrin rẹ.

ORI 28.

**Ẹni-buburu ati olododo eniyan.**

ENIYAN buburu sá nigba ti ẹnikan kò le e: ṣugbọn olododo laya bi kinniun. (Lef 26:17; Psm 53:5.)

2. Nipa irekọja ilẹ ni awọn ijoye ndi pupọ, ṣugbọn nipa awọn amoye ati onimọ̀ eniyan, ni a nmu ilẹ pẹ titi. (Owe 11:11.)

3. Aláìní ti o nni aláìní lara, o dabi àgbàlọ òjò ti ko fi ounjẹ silẹ. (Matt 18:28.)

4. Awọn ti o kọ òfin silẹ a maa yin eniyan buburu: ṣugbọn awọn ti o pa òfin mọ́ a maa binu si wọn. (Rom 1:32; 1 A.Ọba 18:18.)

5. Ọye idajọ kò ye eniyan buburu: ṣugbọn awọn ti nṣe afẹri Oluwa moye ohun gbogbo. (Psm 92:6; Jhn 7:17; 1 Kor 2:15.)

6. Talaka ti nrin ninu iduro-ṣinṣin rẹ, o sàn jù alárékereké iwà, bi o tilẹ ṣe ọlọ́rọ̀. (Owe 19:1; ẹsẹ 18.)

7. Ẹnikẹni ti o pa ofin mọ́, o ṣe ọlọgbọn ọmọ: ṣugbọn ẹni ti o ṣe ẹlẹgbẹ jẹgúdújẹrá, o tì baba rẹ ni oju. (Owe 23:20.)

8. Ẹni ti o fi èlé ati èrè aiṣootọ́ sọ ọrọ̀ rẹ di pupọ, o ko o jọ fun ẹni ti yoo ṣe aanu fun awọn talaka. (Lef 25:36; Owe 13:22; 14:31.)

9. Ẹni ti o mu etí rẹ kuro lati gbọ òfin, ani adura rẹ paapaa yoo di irira. (Psm 66:18; Owe 15:8.)

10. Ẹnikẹni ti o mu olododo ṣina si ọ̀nà buburu, oun tikararẹ yoo bọ si ihò, ṣugbọn ẹni-iduro-ṣinṣin yoo jogun ohun rere. (Owe 26:27; Matt 6:33; Heb 6:12.)

11. Ọlọ́rọ̀ gbọ́n ni ojú ara rẹ: ṣugbọn talaka ti o moye ridi rẹ. (Owe 26:5,12; 18:17.)

12. Nigba ti awọn olododo eniyan ba nyọ̀, ogo nla yoo wà; ṣugbọn nigba ti eniyan buburu ba dide, eniyan a sa pamọ́. (Owe 11:10.)

13. Ẹni ti o bo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ mọ́lẹ̀ ki yoo ṣe rere: ṣugbọn ẹnikẹni ti o jẹwọ́ ti o si kọ ọ silẹ yoo ri aanú. (Psm 32:3,5.)

14. Ibukun ni fun ẹni ti o bẹ̀rù nigbagbogbo: ṣugbọn ẹni ti o ba sé áyà rẹ̀ le ni yoo ṣubu sinu ibi. (Psm 16:8; Rom 2:5.)

15. Bi kinniun ti nke ramùramu, ati ẹranko beari ti nfi ebi sare kiri; bẹẹ ni ẹni buburu ti o joye lori awọn talaka. (1 Pet 5:8; Matt 2:16.)

16. Ọmọ-alade ti o ṣe aláìmòye pupọ ni nṣe ìwà-ìkà pupọ pẹlu: ṣugbọn eyi ti o korira ojukokoro yoo mu ọjọ rẹ pẹ.

17. Eniyan ti o ba hù iwa-ìkà si ẹ̀jẹ̀ ẹnikeji, yoo maa sá pamọ sinu ihò: ki ẹnikẹni máṣe da a lẹkun. (Gen 9:6; Eks 21:14.)

18. Ẹnikẹni ti o ba nrin déédé ni yoo là: ṣugbọn ẹni ti o nfi àyídáyidà rin loju ọ̀nà meji, yoo ṣubu sinu ọ̀kan ninu wọn. (Owe 10:9,25; ẹsẹ 6.)

19. Ẹni ti o ba ro ilẹ rẹ̀ yoo ni ọ̀pọ̀ ounjẹ: ṣugbọn ẹni ti o ba ntọ̀ eniyan asán lẹhin yoo ni òṣì tó. (Owe 12:11.)

20. Olootọ eniyan yoo pọ̀ fun ibukún: ṣugbọn ẹni ti o kanju lati là ki yoo ṣe alaijiya. (Owe 10:6; ẹsẹ 22; 1 Tim 6:9.)

21. Iṣojuṣaju eniyan ko dara: ṣugbọn nitori òkèlè ounjẹ kan, ọkunrin yoo ṣàṣìṣe. (Owe 18:5; Esk 13:19.)

22. Ẹni ti o kanju lati la, ó ni ojú ìlara, ko si ro pe òsì nbọwa ta oun. (Owe 23:6; ẹsẹ 20.)

23. Ẹni ti o ba eniyan wi yoo ri ojurere ni ikẹhin ju ẹni ti nfi ahọ́n pọn ọn lọ. (Owe 27:5,6.)

24. Ẹnikẹni ti o ba njà baba tabi iya rẹ̀ lólè, ti o si wi pe, "Ki iṣe ẹ̀ṣẹ̀", oun naa ni ẹgbẹ apanirun. (Owe 19:26; 18:9.)

25. Ẹni ti o ni iwọra ni àyà, á rú ìjà soke, ṣugbọn ẹni ti o gbẹkẹ rẹ le Oluwa ni a o mu sanra. (Owe 15:27; 29:25.)

26. Ẹni ti o gbẹkẹ le àyà ara rẹ̀, aṣiwère (omugọ) ni; ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba nfi ọgbọ́n rìn, oun ni a o gbà là. (Owe 3:5; ẹsẹ 18.)

27. Ẹni ti o ba nfi fun aláìní ki yoo ṣe alaini: ṣugbọn ẹni ti o mu oju rẹ kuro, yoo gba ègún púpọ̀. (Deut 15:7; Owe 19:17; 21:13.)

28. Nigba ti eniyan buburu ba dide, awọn eniyan a sa pamọ́: ṣugbọn nigba ti wọn ba ṣègbé, awọn olododo a maa pọ̀ si i. (ẹsẹ 12.)

ORI 29.

**Ijọba ẹni-olododo.**

ENI ti a bá nbáwi ti ó wa ọrùn kì, yoo parun lójijì, láìsí àtúnṣe. (1 Sam 2:25; 2 Kro 36:16; Owe 6:15.)

2. Nigba ti awọn olododo wà lori oyè, awọn eniyan á yọ̀; ṣugbọn nigba ti eniyan buburu ba gori oyè, awọn eniyan a kẹ́dùn. (Est 8:15; Owe 28:15.)

3. Ẹnikẹni ti o fẹ ọgbọ́n, a mu baba rẹ̀ yọ̀: ṣugbọn ẹni ti o nba panṣaga kẹgbẹ, á ba ọrọ̀ rẹ̀ jẹ́. (Owe 10:1; 5:9,10; Luk 15:13.)

4. Nipa idajọ ni ọba nmu ilẹ tòrò: ṣugbọn ẹni ti o ba ngba ọrẹ yoo bi i ṣubu.

5. Ẹni ti o npọn ẹnikeji rẹ̀, ta àwọn silẹ fun ẹsẹ rẹ̀. (Psm 5:9.)

6. Ninu irekọja eniyan ibi, ìkẹ́kùn nbẹ: ṣugbọn olododo a maa kọrin, a si maa yọ̀. (Owe 22:5; Eks 15:1.)

7. Olododo a maa ro ẹ̀tọ́ talaka: ṣugbọn eniyan buburu ko bìkítà fún òye nkan bẹẹ. (Job 29:16; Psm 41:1.)

8. Awọn ẹlẹgàn eniyan dá ìrúkèrudò si ìlú: ṣugbọn awọn ọlọgbọ́n eniyan ṣẹ́ri ibinu kúrò. (Owe 11:11; 16:14.)

9. Bi ọlọgbọn eniyan ka nbá aṣiwere (òmùgọ̀) eniyan jà, bi o npariwo-ìbínu ni, tabi o nrẹrin, ki yoo dakẹ ẹnu.

10. Awọn eniyan-ẹ̀jẹ̀ korira ẹniduro-ṣinṣin: ṣugbọn àwọn olododo a maa ṣe afẹri ọkàn rẹ̀. (1 Jhn 3:12.)

11. Aṣiwère (omugọ) a sọ gbogbo inu rẹ̀ jade: ṣugbọn ọlọgbọ̀n a pa á mọ́ di igba ikẹhin. (Owe 12:16; 19:11.)

12. Bi ijoye ba feti si ọ̀rọ̀-èké, gbogbo awọn iranṣẹ rẹ̀ ni yoo buru.

13. Talaka ati aninilara eniyan pàdé pọ̀: Oluwa ni o ntan imọlẹ si ojú awọn mejèjì. (Psm 13:3.)

14. Ọba ti o fi otitọ ṣe idajọ tálákà, itẹ́ rẹ yoo fi idí múlẹ̀ laelae. (Psm 72:4; Isa 11:4; Owe 16:12; 25:5.)

15. Pàṣán ati ibawi funni ni ọgbọ́n: ṣugbọn ọmọ ti a ba fi silẹ̀ fun ara rẹ̀, yoo dojuti ìyá rẹ̀. (Owe 13:24; 10:1.)

16. Nigba ti awọn eniyan buburu ba npọ̀ si i, irekọja a pọ̀ si i: ṣugbọn awọn olododo yoo rí iṣubu wọn. (Psm 37:36; 58:10; 91:8; 92:11.)

17. Tọ́ ọmọ rẹ, yoo si fun ọ ni isinmi; yoo si fi inu-didùn si ọ ni ọkàn. (ẹsẹ 15; Owe 10:1.)

18. Nibi ti ìsọtẹ́lẹ̀ kò sí, eniyan á yapa, ṣugbọn ibukun ni fun ẹni ti o pa ofin mọ́. (1 Sam 3:1; Amos 8:11,12; Jhn 13:17.)

19. Nipa ọ̀rọ̀-ìkìlọ̀ ọmọ-ọ̀dọ̀ kii gba ìbáwí, bi o tilẹ ye e kì yoo kọbi-ara sii.

20. Iwọ ri eniyan ti o yara ni ọ̀rọ̀ rẹ̀? ireti nbẹ fun aṣiwère (omugọ) jù fún un lọ. (Jms 1:19; Owe 26:12.)

21. Ẹni ti o ba fi ìkẹ́ tọ́ ọmọ-ọdọ rẹ̀ lati ìgbà-ewè wa, yoo jẹ ọmọ fun un nikẹhin.

22. Ẹni ibinu rú ìjà sókè, ati ẹni ikannu pọ̀ ni irekọja. (Owe 15:18; 17:19.)

23. Igberaga eniyan ni yoo rẹ̀ ẹ silẹ̀: ṣugbọn onirẹ̀lẹ̀ ọkàn ni yoo gba ọlá. (Job 22:29; Isa 66:2; Dan 4:30; Matt 23:12.)

24. Ẹni ti o ko ẹgbẹ́ olè korira ọkàn ara rẹ̀: o ngbọ́ ìfiré, kò sì sọ síta. (Lef 5:1.)

25. Ìbẹ̀rù eniyan ni nmu ikẹ́kùn wá: ṣugbọn ẹnikẹni ti o gbẹkẹ rẹ̀ lé Oluwa ni a o gbe lékè. (Gen 12:12; Psm 91:1–16.)

26. Ọpọlọpọ eniyan ni o nwá oju-

rere ìjòyè: ṣugbọn idajọ eniyan ni o nti ọdọ Ọluwa wá. (Isa 49:4.)

27. Alaiṣootọ eniyan, irira ni si awọn olododo: ẹni ti o duro-ṣinṣin ní ọ̀nà rẹ̀, irira ni si eniyan buburu.

## ORI 30.

**Ọ̀rọ̀ afiyèsi.**

ỌRỌ Aguri, ọmọ Jake, ọ̀rọ̀ ẹ̀kọ́ ti ọkunrin naa ti sọ, fun Itieli, ani fun Itieli ati Ukali. (Owe 31:1.)

2. "Nitootọ emi gò ju ẹlomiran lọ, emi ko si ni ìmòye ti eniyan. (Psm 73:22.)

3. Emi ko tilẹ̀ kọ ọgbọ́n, emi ko tilẹ ni ìmọ̀ ohun mímọ́. (Owe 9:10.)

4. Tani o ti goke lọ si ọrun, tabi ti o si sọkalẹ wa? Tani o ko afẹ́fẹ́ jọ ni ọwọ́ rẹ̀? Tabi o di omi sinu aṣọ? Tabi o fi gbogbo opin ayé lẹ ilẹ̀? Orukọ rẹ̀ ti njẹ, ati orukọ ọmọ rẹ̀ ti njẹ, bi iwọ ba le mọ ọn?" (Jhn 3:13; Psm 104:3; Isa 40:12; Job 38:8,9; Isa 45:18.)

5. Gbogbo ọ̀rọ̀ Oluwa ni funfun: oun ni asà fún gbogbo awọn ti o gbẹkẹ wọn le e. (Psm 12:6; 18:30; 84:18.)

6. Iwọ máse fi kun ọ̀rọ̀ rẹ̀, ki oun ma baa ba ọ wi, a si mu ọ ni èké. (Deut 4:2; 12:32; Ifh 22:18.)

7. Ohun meji ni mo tọrọ lọdọ rẹ; maṣe fi wọn du mi ki emi tó kú.

8. Mu asan ati èké jinna si mi: maṣe fun mi ni òṣì, maṣe fun mi ni ọrọ̀; fi ounjẹ ti o to fun mi. (Matt 6:11.)

9. Ki emi ma baa yó jù, ki emi si sẹ́ ọ, pe "Tani Oluwa?" tabi ki emi ma baa tòṣì, ki emi si jalè, ki emi si ṣẹ̀ sí orukọ Ọlọrun mi. (Deut 8:12; Neh 9:25; Job 31:24; Hos 13:6.)

**Ìtò-lẹsẹẹsẹ òwe.**

10. Máṣe fi ẹ̀sùn iranṣẹ sun ọ̀gá rẹ̀, ki o ma baa fi ọ bú, ki iwọ ma baa jẹbi. (Onws 7:21.)

11. Awọn kan wa ti nfi baba wọn bú, ti kò si sure fun ìyá wọn. (Owe 20:20.)

12. Awọn kan wa, ti o mọ́ ni ojú ara wọn, ṣugbọn a ko i ti wẹ ẹ nu kuro ninu èérí rẹ̀. (Luk 18:11.)

13. Awọn kan wa, yee, ojú wọn ti gbẹga tó! ipẹnpeju wọn si gbe sókè. (Psm 131:1; Owe 6:17.)

14. Awọn kan wa, ehín ẹni ti o dabi idà, èrigì wọn dabi ọ̀bẹ, lati jẹ tálákà run kuro lori ilẹ̀, ati awọn alaini kuro ninu awọn eniyan. (Job 29:17; Psm 52:2; 14:4; Amos 8:4.)

15. Eeṣú ní ọmọbinrin meji, ti nkigbe pe, "Muwa! muwa!" Ohun mẹta ni nbẹ ti a ko le tẹ lọ́rùn lae, àní mẹrin ni ki i wi pe, "Ó tó!"

16. Isà-òkú, ati inu àgàn; ilẹ ti ki i kun fun omi; ati iná ti ki i wi pe, ó tó. (Owe 27:20.)

17. Oju ti o sín baba rẹ̀ jẹ, ti o gan gbigbọ ti ìyá rẹ̀, ẹyẹ-iwo ẹ̀bá odò ni yoo yọ ọ jade, ọmọ idì ni yoo fi ṣe ìjẹ. (Gen 9:22; Owẹ 23:22; Deut 28:26.)

18. Ohun mẹta ni nbẹ ti o ṣe iyanu fun mi, nitootọ, mẹrin ni emi kò mọ̀.

19. Ọ̀nà idì loju ọ̀run; ọ̀nà ejò lori apata: ọ̀nà ọkọ̀ loju òkun; ati ìwà ọkunrin pẹlu wundia.

20. Bẹẹ ni ìwà àgbèrè obinrin: o jẹun, o si nu ẹnu rẹ̀ nù, o si wi pe, "Emi ko ṣe buburu kan." (Owe 5:6.)

21. Nitori ohun mẹta, ayé a di rudurudu, ati labẹ̀ mẹrin ni kò lè dúró.

22. Iranṣẹ, nigba ti o jọba; ati aṣiwère, (omugọ) nigba ti o yọ̀ fun ounjẹ; (Owe 19:10.)

23. Fun obinrin, ti a korira, nigba ti a sọ ọ di ìyálé; ati fun iranṣẹ-binrin, nigba ti o di àrólé ọ̀gá rẹ̀ obinrin.

24. Ohun mẹrin ni nbẹ ti o kereju lori ilẹ̀, sibẹ wọn gbọ́n, wọn nkọni ni ẹ̀kọ́:

25. Alailagbara eniyan ni eera, ṣugbọn wọn npese ounjẹ wọn silẹ ni igba ẹ̀rùn; (Owe 6:6–8.)

26. Alailagbara eniyan ni ehoro, ṣugbọn wọn nṣe iho wọn ni palapala okuta; (Psm 104:18.)

27. Awọn eeṣu ko ni ọba, sibẹ gbogbo wọn a jade lọ ni ọwọ́-ọwọ́;

28. Ọmọ́ọ̀lé ti a lè mú dání ní ọwọ, sibẹ o nbẹ ni aafin ọba.

29. Ohun mẹta ni nbẹ ti nrin ìrìn rere, nitootọ́, mẹrin ni o dara ni ìrìn ririn.

30. Kinniun ti o lagbara julọ ninu ẹranko, ti ko si pẹhinda fun ẹnikan. (Ondj 14:18; Mika 5:8.)

31. Ẹṣin ti a dì lẹ́gbẹ̀ẹ́; ati obukọ; ati ọba laarin awọn eniyan rẹ̀.

32. Bi iwọ ba ti hùwà-òmùgọ̀ ni gbigbe ara rẹ soke, tabi bi iwọ ba ti ronu ibi, fi ọwọ́ rẹ lé ẹnu rẹ. (Job 21:5; 40:4; Mika 7:16.)

33. Nitootọ́, fífún wara ni nmu ọ̀rí-àmọ́ wá, ati fífọn imú ni nmu ẹ̀jẹ̀ jade; bẹẹ ni rírú ibinu soke ni nmu ìjà wa. (Owe 10:12; 29:22.)

## ORI 31.

**Ọ̀rọ̀ Lemueli ti ìyá rẹ kọ ọ.**

ỌRỌ̀ Lemueli, ọba, ọ̀rọ̀-ẹ̀kọ́ ti ìyá rẹ̀ kọ ọ. (Owe 30:1.)

2. Kinni, ọmọ mi? Ki si ni, ọmọ inu mi? Ati kinni, ọmọ ẹ̀jẹ̀ mi? (Isa 49:15.)

3. Máṣe fi agbara rẹ fun awọn obinrin, tabi ìwà rẹ fun awọn obinrin ti nba awọn ọba jẹ. (Owe 5:9; Deut 17:17; 1 A.Ọba 11:1; Neh 13:26.)

4. Ki i ṣe fun awọn ọba, Lemueli, ki i ṣe fun awọn ọba lati mu ọtí-waini; bẹẹ ni ki i ṣe fun awọn ọmọ alade lati fẹ ọtí lile: (Onws 10:17; Owe 20:1.)

5. Ki wọn ma baa mu, wọn a si gbagbe òfin, wọn a si yi idajọ awọn olupọnju. (Hos 4:11.)

6. Fi ọti lile fun ẹni ti o mura tan lati ṣègbé, ati ọti-waini fun awọn oninu bíbàjẹ́.

7. Jẹ ki o mu, ki o si gbagbe aini rẹ̀, ki o ma si ranti oṣi rẹ̀ mọ́.

8. Ya ẹnu rẹ fun odi, fun ẹ̀tọ́ gbogbo awọn ti ó jẹ́ ọmọ ìparun. (Job 29:12-17.)

9. Ya ẹnu rẹ, fi ododo ṣe idajọ́, ki o si gbèjà talaka ati alaini. (Lef 19:15; Deut 1:16.)

**Obinrin wọ́n ju iyùn lọ.**

10. Tani yoo ri obinrin oni ìwà-rere? Nitori ti iye rẹ̀ kọjá iyùn. (Owe 12:4; 19:4.)

11. Àyà ọkọ rẹ̀ gbẹkẹlẹ e laibẹru, bẹẹ ni oun ki yoo ṣe alaini èrè iṣẹ́.

12. Rere ni obinrin naa yoo maa ṣe fun un, ki i ṣe buburu ni ọjọ ayé rẹ̀ gbogbo.

13. Obinrin naa yoo maa ṣafẹri irun-agutan ati ọ̀gbọ̀, a si maa fi ọwọ ìfẹ́ rẹ̀ ṣiṣẹ́. (ẹsẹ 21–24.)

14. O dabi ọkọ̀ oniṣowo: o si mu ounjẹ rẹ̀ lati ọ̀nà jínjìn rere wá.

15. Oun a si dide nigba ti ilẹ̀ koiti i mọ́, a si fi ounjẹ fun eniyan ile rẹ̀, ati iṣẹ òòjọ́ fun awọn ọmọbinrin rẹ̀. (Rom 12:11; Luk 12:42.)

16. O kiyesi oko, o si ra a: ere ọwọ́ rẹ̀ ni o fi gbin ọgbà-àjàrà.

17. O fi agbara gba ẹ̀gbẹ́ rẹ̀ ni ọ̀já, o si mu apá rẹ mejeji le.

18. O kiyesi i pe ọ̀já oun dara: fitila rẹ̀ kò kú ní òru.

19. O fi ọwọ́ rẹ̀ le kẹ̀kẹ́-òwú, ọwọ́ rẹ̀ si di iranwu mu.

20. O na ọwọ́ rẹ̀ si talaka; nitootọ́, ọwọ́ rẹ̀ si kan alaini. (Ef 4:28; Heb 13:16.)

21. Oun ko si bẹru òjò-dídì fun awọn ara ile rẹ̀; nitori pé gbogbo awọn ara ile rẹ̀ ni a wọ̀ ni aṣọ iṣẹpo meji. (1 Sam 1:24.)

22. Oun si wun aṣọ títẹ́ fun ara rẹ̀; ẹwu daradara ati elésè àlùkò ni aṣọ rẹ̀.

23. A mọ ọkọ rẹ̀ ni ẹnu-bode, nigba ti o ba jokòó pẹlu awọn agba ilẹ naa. (Rut 4:1,11; Owe 12:4.)

24. O da aṣọ ọ̀gbọ̀ daradara, o si ta a, pẹlupẹlu o fi ọ̀já àmùrè fun oniṣòwò tà.

25. Agbara ati ìyìn ni aṣọ rẹ̀; oun o si yọ̀ si ọjọ ti nbọ. (ẹsẹ 17.)

26. O fi ọgbọn ya ẹnu rẹ̀; ati ni ahọn rẹ̀ ni ofin iṣeun. (Owe 10:31.)

27. O fi ojú silẹ wo iwa awọn ara ile rẹ̀, kò sì jẹ ounjẹ ìmẹ́lẹ́. (Owe 19:15.)

28. Awọn ọmọ rẹ dide, wọn si pe e ni alabukun-fun, ati baale rẹ pẹlu, oun si fi iyìn fun un.
29. "Ọpọlọpọ awọn ọmọbinrin ni o huwa rere, ṣugbọn iwọ ta gbogbo wọn yọ!" (Owe 12:4.)
30. Ojú daradara ni ẹ̀tàn, ẹwa si jasi asán: ṣugbọn obinrin ti o bẹru Oluwa, oun ni ki a fi iyin fun. (Owe 6:25; 22:4.)
31. Fi fun un ninu èso-iṣẹ ọwọ́ rẹ̀; jẹ ki iṣẹ ọwọ́ rẹ̀ yìn ín ní ẹnubode.

21

# IWE ONIWAASU

**(B.C. 977)**

ORI 1.

**Asán ni làálàá eniyan.**

ỌRỌ oniwaasu, ọmọ Dafidi, ti o jọba ni Jerusalẹmu. (ẹsẹ 12; Onws 7:27; 12:8–10.)
2. Asán ninu asán, oniwaasu naa wi pe, asán ninu asán; gbogbo rẹ asán ni! (Psm 39:5,6; 62:9; 144:4; Onws 12:8.)
3. Èrè kinni eniyan jẹ ninu gbogbo làálàá rẹ̀ ti o ṣe lábẹ́ ọ̀run? (Onws 2:22; 3:9.)

**Iran kan nlọ iran kan nbọ.**

4. Iran kan nlọ, iran miran si nbọ̀: ṣugbọn ayé duro titi lae. (Psm 104:5; 119:90.)
5. Òòrùn pẹlu là, òòrùn si wọ̀, o si yara lọ si ipo rẹ̀ nibi ti o ti là. (Psm 19:5,6.)
6. Afẹfẹ nfẹ lọ sihà gusù, o si yipada siha ariwa; o si nlọ sihin sọhun titi, afẹfẹ si tun pada gẹgẹ nipa ayika rẹ̀. (Onws 11:5; Jhn 3:8.)
7. Odò gbogbo ni nṣan sinu òkun; ṣugbọn òkun kò kún nibi ti awọn odò ti nṣan wa, nibẹ ni wọn si tun pada lọ.
8. Ohun gbogbo kun fun àárẹ̀; eniyan kò lè sọ ọ: iran ki i sú oju, bẹẹ ni eti ki i kún fún gbigbọ. (Owe 27:20.)
9. Ohun ti o wà, oun ni yoo si wà; ati eyi ti a ti ṣe ni èyí ti a o ṣe; kò si ohun titun labẹ òòrùn. (Onws 2:12; 3:15.)
10. Ohun kan wa nipa eyi ti a wi pe, "Wo o, titun ni èyí!" o ti wà naa nigba atijọ, ti o ti wà ṣaaju wa.
11. Kò si iranti ohun iṣaaju; bẹẹ ni iranti ki yoo si fun ohun ikẹhin ti nbọ wa, ṣelẹ̀ lọdọ awọn ti nbọ nigba ikẹhin. (Onws 2:16; 9:5.)

**Asán ni ọgbọn eniyan.**

12. Emi oniwaasu jọba lori Israẹli ni Jerusalẹmu. (ẹsẹ 1.)
13. Mo sì fi àyà mi si ṣiṣe afẹri ati iwadi nipa ọgbọn ohun gbogbo ti a nṣe labẹ ọrun, làálàá kikan yií ni Ọlọrun fi fun awọn ọmọ eniyan lati ṣe làálàá ninu rẹ̀. (ẹsẹ 17; Onws 3:10.)
14. Mo ti ri iṣẹ gbogbo ti a nṣe labẹ òòrùn; si kiyesi i, asán ni gbogbo rẹ ati ìmúlẹ̀mófo. (Onws 2:11,17.)
15. Èyí ti o wọ́, a ko le mu un tọ́: ati ẹ̀yí ti o lábùkù, a kò lè ka a. (Onws 7:13.)
16. Mo si ba àyà mi sọrọ wi pe, "Kiyesi i, mo ni ọgbọn nla, àní ju gbogbo wọn lọ ti o ti ṣaaju mi ni Jerusalẹmu; àyà mi si ri ohun pupọ nla ti ọgbọn ati ti ìmọ̀." (1 A.Ọba 3:12,13; 4:30; 10:23; Onws 2:9.)
17. Nigba ti mo fi àyà mi si mimọ ọgbọn, ati lati mọ isínwin ati iṣe-òmùgọ̀: nigba naa ni mo mọ̀ pe, eyi pẹlu jẹ imulẹmofo. (Onws 2:3,12; 7:23,25.)
18. Nitori pe ninu ọgbọn pupọ ni ibanujẹ pupọ wà, ẹni ti o si nsọ ìmọ̀ di pupọ, o nsọ ikaanu di pupọ. (Onws 12:12.)